# Lori Awọn Ìyẹ̀ Ápá Àdàbà Funfun Bi Òjò-Dídì Kan

Shreveport, Louisiana USA

Ojo 28, Osu Kokanla, 1965

1 Ẹ jẹ ki a tẹ ori wa ba: Oluwa ọ̀wọ́n a dúpẹ́ lọwọ Rẹ ni àsálẹ́ yii fun ileri ti ìpadàbọ̀ Oluwa Jesu, níbi ti a o ti pàdé, ninu ìpade nla kan ti ki yoo ni òpin, pẹlu ayọ̀ ati orin, ti a o fi maa yin Ọ ninu gbogbo awọn ìgbà ti ki yoo ni opin ti n bọ wa. A beere fun awọn ibukun Rẹ lori ipade ni aṣalẹ yii. A bèèrè fun awọn ibukun Rẹ lori àgó yii, lori awọn osisẹ, Olusọ-agutan ijo yii, lori awọn álabásiṣẹpọ, awọn oluso-agutan alabasisẹpọ, ati lori gbogbo awọn enìyàn.

A beere lọwọ Rẹ pe ki O bukun fun awọn wọnyi, Oluwa, ti wọn ti ti ọ̀pọlọ̀pọ̀ ibùsọ̀ wa si ìpàdé yii. Ẹ gbe ọwọ́ àánú yin le wọn lórí bi wọn yoo ṣe maa rin ìrinàjò pada si ile wọn. Ẹ gba bẹẹ fun wa, Oluwa n jẹ ki a pade ni ọpọlọpọ igba sii ni ihin yii, ti a n pe ni Ile Ọlọ́run lati jọsin. Ẹ bukun awọn ti wọn n gbọ wa laṣalẹ yii, Oluwa, nipa ẹ̀rọ ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀. Jẹ ki gbogbo awọn ti a ko i tii gbala ri Jesu Kristi gẹgẹ bi Olugbala wọn ni aṣalẹ yii; Ẹ wo gbogbo awọn aláìsàn ati aláìlera san. Baba iranṣẹ Rẹ n gunlẹ fun isin, ni orukọ Jesu, Amin.

2 Ki Oluwa bùkún ẹni kọọkan yin. Inu mi dun jọjọ lati wa nihin laṣalẹ yii. Mo sẹsẹ wole ni nigba ti Arakunrin Ernie n kọ abala ti o kẹyin ninu orin wọn lori Iyẹ Apa Adaba kan. Dajudaju éwi ti o rẹwa ni. Dajudaju o rẹwa, mo si mọ pe o ba akoko mu. Nitorinaa bayi awa …. a dupẹ gan n.

Ati fun gbogbo ẹyin eniyan ti ẹ n gbọ wa ni aṣalẹ yii ni gbogbo orilẹ-ede, inu mi iba dun ki a ni ẹ wa nihin lati ri iduro, ifojusọna ti o wa loju awọn eniyan yii, bi wọn ti kun inu ile fọ́fọ́ laṣalẹ yii, ti wọn n ni akoko ti o dara.

A fẹ dupẹ lọwọ Arakunrin Jack Moore, ati Arabinrin Moore ati Arakunrin Noel, Arakunin Boutilere, Arakunrin Brown ati gbogbo awọn ẹlẹgbẹ wọn nihin ati gbogbo agọ, ati gbogbo awọn oṣiṣẹ fun pípè ti ẹ pe wa pada.

3 O jẹ ohun kan gẹlẹ ti … a ko lee sọ wi pe o ṣeesì sẹlẹ̀, o jẹ ọwọ Ọlọ́run ti o jẹ ki o ṣeéṣe. Arakunrin kan wa nihin yii ti o la ala ni igba kan sẹyin nipa ohun ti o n ṣele yii. O sọ wipe mo duro ti mo wọ sòkòtò gbọọrọ funfun ati bata India ti a fi awọ agbọrin ṣe. Bi mo ṣe n duro niyi nigba ti mo pe Arakunrin Jack fun ipade ihin yii. Bẹẹ gẹlẹ, ni Carson, Colorado, bata India oni awọ agborin ati sokoto Levi funfun gbọọrọ, Arakunrin Leo, bi ẹ ba n tẹtisi mi loni, n o pade yin ni iseju diẹ si igba ti a wa yii. Nitori naa, nibẹ ni a ti bí ìpàdé yii, nibẹ gan an.

4 Wayii alẹ Sọnde niyi, mo mọ wipe ọpọlọpọ yin yoo wakọ ni gbogbo oru oni lọ sílé. Awọn miiran ninu yin yoo wa ọkọ̀ ni òwúrọ̀. Mo ni ọjọ meji ti n o fi wakọ. Nitori naa, a ki yoo gba pupọ ninu akoko yin. Mo si ti gbiyanju lati ri wi pe aṣalẹ yii yoo jẹ alẹ igba-a-ni, alẹ ti Arakunrin Brown, Arakunrin Jack, ati gbogbo wa maa n gbadura fun awọn alaisan ni ọna kan naa bi a ṣe maa n ṣe nigba naa.

Wayi, n jẹ e n gbọ mi lẹyin lohun? Mo saa n gbiyanju ni lati ti awọn gbohun-gbohun wọnyi silẹ nítorí pe ohùn mi ti ha.

5 Ati bayi, mo fẹ …. Ohun kekere kan ni, ohun kekere ti o ṣẹlẹ. Nigba diẹ sẹyin, wọn sọ fun mi pe arakunrin kan wa, boya o tilẹ wa ninu ipade yii ni irọlẹ yii, ti o ṣẹṣẹ jade kuro ni awọn ijọ aládàámọ̀, o wa si Shreveport, o si fẹ gbọ nipa Ọrọ Ọlọ́run-Ti-Ọjọ Oni. Ọna si dàrú fun un ko mọ ibi ti o wa mọ, nitori naa, o lọ si ìgboro. O rii wi pe awọn eniyan kan ko ara wọn jọ, o wa sọ wipe, "Njẹ nihin ni Billy Branham ti fẹ waasu?"

Nwọn daa lohun wi pe, "Rara o, ibi ti Billy Graham ti n waasu nipa sinimọ́ ni."

O wi pe, "o daa, mo tọrọ gafara, ibi ti mo n wa kọ niyi."

O wa, o si wipe, "Nibo ni n'o lọ, Oluwa?" O ni oun bẹrẹ sii rin lọ si òpópònà pàtàkì yii, o ni oun ko mọ ohun ti o jẹ, sugbọn ile ijọsin nla kan wa ni opin òpópònà naa, Òpópònà Texas ni. Agbelebu funfun kan wa ni oke ile ijọsin kan. O ni Oluwa sọ fun oun pe "sa a maa tẹ siwaju." O ni nigba ti oun de ibẹ ohun kan wa, o wi pe, "O daa, ibi yii ni o ni lati jẹ, ọpọlọpọ ọkọ ayọkẹlẹ wa nibẹ." O wi pe iyawo kan ati ọkọ iyawo kan jade, wọn n rin jade kuro ninu ile ijọsin naa. Iyẹn jẹ ni aṣalẹ ana, igbeyawo kan waye, o ni o wa ye oun. Oluwa wi pe, "wayi, bi o ṣe jẹ ni yẹn. O n jade kuro ninu awọn ijọ aladamọ lati wọ inu Iyawo, lati lọ pẹlu Ọkọ Iyawo.

6 Mo n ba iyawo mi sọrọ, nigba ti a n rin bọ ni òpópónà naa, bi òṣùpá ati ìráwọ̀ ti n rọ sori agbelebu naa, bi a ṣe wọle. Mo ro wipe mo maa n wo awọn nnkan kekere bẹẹ nitori pe wọn maa n wa nibamu pẹlu igbagbọ mi ninu Ọlọ́run ati iṣe-iriju-iwaasu mi.

Mo n ro ni aṣalẹ yii ni Tucson, o ṣẹlẹ wi pe Victor La Deux, ti o jẹ ara Faranse, o jẹ ojulowo ọmọbibi orilẹ-ede Faranse. Mo gbagbọ wi pe mo n sọ fun yin ni ijelo, pe nigba ti mo waasu tan, ti mo n gbiyanju lati ya igbagbọ ninu ijọ aladamọ kuro ninu ẹsin igbagbo ojulowo… Ti ọkunrin kan si n ṣe atako mi lori rẹ, oun jẹ ọmọ ijọ aladamọ ti n fi-ede-ajeji sẹri-Ẹmi Mimọ ti o gbaju gbaja.

Nitori naa, Danny Henry, mo ro wi pe o jẹ ibatan osere ori sinimọ́ kan tabi ohun ti o jọ bẹẹ, o si jẹ ọmọ-ijọ

onitẹ̀bọmi; bẹẹ ni o sare wa si ibi aga-ìwáásù, o si gbe awọn ọwọ rẹ le mi o si wi pe, “Arakunrin Branham, mo ro wi pe eleyi kii ṣe ohun ti ko bu ọla fun Ọlọ́run o, sugbọn ohun ti ẹ ṣẹṣẹ sọ tan ni a lee pe ni Iwe Ifihan Ori-kẹtalelogun.” Nigba ti o si bẹrẹ si sọ nnkan miiran, o bẹrẹ sii sọrọ ni ede miiran.

Awọn ara Faranse mẹta … Obìnrin ara Faransé kan (o tobi, o jẹ obìnrin ti o sanra, o dudu, o wa lati Louisaiana, o ṣeeṣe ki o wa ni ijoko nihin ni aṣalẹ yii), kọ ohun ti o sọ silẹ sinu iwe pelebe kan. Lẹyin naa, Victor La Deux, oniwaasu kan, kọ ohun kan naa silẹ, wọn si bẹrẹ sii fi ohun ti wọn kọ we ara wọn, tabi wọn fẹ bẹrẹ si fi we ara wọn. Ọkunrin kan ti irun rẹ mọ fẹẹrẹ (onirun pupa) dide lati ẹyin lẹyin ni ibi ti o ti ri aaye lẹyin, dide o si n rin bọ, o si fẹ ri awọn iwe ti wọn kọ. Oun jẹ ogbufọ Ede Faranse fun Igbimọ Awọn Orilẹ-Ede Agbaye. Gbogbo ohun ti awọn mẹtẹẹta kọ si jẹ bakan naa.

Ohun ti o sọ niyi; “Nitori pe iwọ ti yan ọna ti o niran ni … Iwo ni o yan an, o ti yan nipa ara rẹ (nitori a mọ wi pe Mose ni lati ṣe iyan tirẹ)” O wi pe, “Eyi ni ọna ti o tọ ti o si yẹ gẹlẹ nitori Ọna Temi ni. Aa Ipinnu Ologo ni eyi ti iwọ yan!” O wi pe “Nitori eyi, ipin Ọrun nla n duro de ọ. Eyi ninu ara rẹ ni yoo ṣe, ti yoo si mu wa si imuṣẹ isẹgun nla ninu ifẹ Ọlọ́run.”

Ẹda Ede Faranse mẹtẹẹta si jẹ bakan naa. Mo ro wi pe mo ni ojulowo ẹda naa ninu Bibeli mi ni irọlẹ yi ni (Mo yẹ ẹ wo, ko si nibẹ)

7 Danny Henry, ko gbọ … bii ti ẹmi naa ni, Ede Oyinbo daadaa ki a ma ti sọ wi pe yoo gbo Faranse. Bi o ba kiyesi nibẹ, bi Ede Faranse ti ri niyẹn, wọn yoo fi ọrọ iṣe ṣaaju ọrọ ti n pọn ọrọ iṣe. Itumọ awọn mẹtẹẹta ri bakan naa gẹlẹ.

Danny Henry, nigba kan sẹyin, o ṣe…. O ṣeéṣe ki Danny maa tẹtisi mi ni irọlẹ yii. Victor La Deux, o ṣeéṣe, nitori mo gbọ wi pe o wa ni Tucson loni. Ati ẹyin ti ẹ wa ni Tucson, ni Ile-Ọlọ́run, ni ago naa ni Ago Tucson naa, nibi ti Arakunrin Green ti jẹ Olusọ-agutan. Mo gbọ wi pe Arakunrin Victor La Deux wa ni ipade agọ kan ni isalẹ Park Avenue nibi ti o ti wọ inu Òpópònà 80, ti ọ ti wa ọna ihin. Ti ẹ ba wa nibẹ ni alẹ ọla ati alẹ ọtunla, nigba-ki-gba, bi yoo ba sẹ pẹ to nibẹ, ẹ lọ gbọ ọ: Danny si le wa nibẹ pẹlu rẹ. O si ṣeeṣe pe wọn n tẹti si mi lati inu Agọ laṣalẹ yii, emi ko mọ.

8 Lẹyin na Danny lọ si Jerusalẹmu, o ni oun fi iha lelẹ ninu iboji lori ibi itẹ́ kan, lori itẹ́ apata kan, ti a tẹ oku Jesu si, ní gẹlẹ ki O to jinde. O si wi pe, “lojijí o wa si ọkan mi”, oun si sa jade, oun bẹrẹ sii sọkún, oun si rin jade. A si dari oun … O jẹ ẹni ti n fi apata dárà. O si lọ si ibi ti a kan agbelebu mọlẹ, o si duro nibẹ… o fọ òkúta kékeré kan, tí ìbú ati òró rẹ baramu, o si fi si apo rẹ, a si dari rẹ lati mu wa si ile.

Nigba ti o mu u de ile, ohun kan sọ fun pe, “Ṣe bọtini ti a n ki bọ ọrùn ọwọ aṣọ ọkunrin meji fun Arakunrin Branham lati inu okuta naa.” O si fi okuta naa sinu omi ti o fi n sisẹ, o si yi awọ rẹ pada kuro ninu okuta laimì si okuta ti o ni aworan ẹjẹ. O si ṣe botini ti a n fi si ọrùn ọwọ́ asọ ọkunrin.

Nigba ti o fi wọn fun mi, ko kiye sii, sugbọn làààrìn awọn bọtini naa ni ila tàààrà ati ila tóóóró wa. Mo wọ wọn ni aṣalẹ yi lati gbadura fun awọn alaisan. Sẹ ẹ rii okuta alawọ ẹjẹ bi ẹjẹ ti n kan pẹlu ila tàààrà, tóóóró ti o la wọn kọja. Ti o wa ni ibamu rẹgi pẹlu asọtẹlẹ rẹ ti o wi pe, “ọna tàààrà, ati ọna tóóóró naa, ṣẹ ẹ ri, ninu asọtẹlẹ naa. Mo fi han an.

Danny, bi o ba n tẹtisimi, iwọ tabi Arakunrin La Deux, eyikeyi ninu yin, alẹ yii yoo jẹ alẹ-igbaani nigba ti a o gbadura fun awọn alaisan. Inu mi dun lati ma rin ninu ona hiha ati ọna tóóóró ni, ọna ti ihinrere, ọna ti Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run pẹ̀lú Oluwa wa Jesu Kristi.

9 Ki Ọlọ́run ki o bukun gbogbo yin. Wayi, o dara lati ba yin sọrọ. N o sọrọ fun igba pipẹ, emi yoo si gba pupọ ninu àkókò yin. Billy sọ wipe awọn ọ̀ọ́dúnrún si irínwó awọn eniyan ni o wa nilẹ lati gba adura fun; nitori naa mo ni lati ṣe kankan pẹlu iwaasu wa bi o ba ti lee ya mi to, lẹyin naa a o gbàdúrà fun awọn alaisan.

Wayi, si ẹyin ti ẹ wa ni Arizona, ni alẹ Satide ti n bọ, a o wa ni (orukọ ilu naa ti sa pa mi lórí) Yuma, Arizona, nibi àpèjẹ naa. Nitori naa ni California, a o tẹ̀síwáju tàààrà ni aarọ Sọnde lọ si Los Angeles ati awọn ibi ti a ya sọtọ pe a o wa.

Ni aṣalẹ yii, mo fẹ mu àkòrí kan wa lati inu Iwe Mimọ.

10 Láyàbá, mo joko ni ile-ounjẹ kan loni, Ile-ounjẹ Morrison; Arakunrin Jack, aya rẹ, emi ati aya mi. Gbogbo wa lọ si ile-ounjẹ Morrison lati ni akoko kekere kan papọ. A ko si tii jade; awọn obinrin naa ko i ti wa papọ̀ ri. Ọmọkunrin kan tọ mi wa, Green ni orukọ rẹ, oun ni baba Arakunrin Pearry Green. O si wi pe, “Arákùnrin Branham, ẹ n sọrọ nipa pinnì Jonny ni alẹ ijeloo.” Ohun ti iyẹn jẹ gan an … kin ni o jẹ? Pinni Bobby. O sọ wi pe, “O n sọrọ nipa pinni jonny.” O wi pe, “Mo ti ni pinni jonny.” O si fi fun mi.

Wayi, pinni jonny niyẹn, ẹyin obinrin. Iyẹn ko ni sisẹ fun irun. Pinni jonny kan. O sọ wipe oun ti n lo fun

ọpọlọpọ ọdun lati mu awọn oju-ewe Bibeli oun mọlẹ. O wa sọ wi pe, “emi yoo fun ọ ni ojulowo pinni jonny.” Nitorinaa, Arakunrin Green, bi o ba wa nihin nibikan tabi bi o ba n tẹtisi mi, pinni jonny yẹn dara gan an o, o tilẹ dii mu daradara ni.

11 Bayi, a fẹ lọ sinu Iwe Mimọ ni kiakika bayi. Mo fẹ ki ẹ si Bibeli pẹlu mi si Orin Davidi 55, ati lẹyin naa Matthew 3, pẹlu. Akori iwaasu mi laṣalẹ yii ni àkòrí orin Arakunrin Ernie. Lori Iye-Apa Adaba Funfun Bii Ojo Didi kan. Wayi, n ko ni lee fi ẹnu ba gbogbo ohun ti mo kọ silẹ ati gbogbo Iwe Mimọ ti mo kọ si ihin, nitori pe n o lo lérèfé, lori awọn diẹ ninu wọn, nitori pe mo ti sèlérí iwaasu naa.

Bi Oluwa ba fẹ, a o lọ si Yuma ni alẹ Satide ti n bọ, mo fẹ waasu lori: Awọn Koṣee-ma-ni fun igbalọsoke awọn Ayanfẹ Kristi,“ bi Oluwa ba fẹ.

12 Ni Orin Davidi 53… ẹ forijimi, Orin Davidi 55

E feti silẹ… [Ẹ forijimi? 55. Bẹẹni sa.]

Feti si adura mi, Ọlọrun; …

ma si ṣe fi ara Rẹ pamọ kuro ninu ẹbẹ mi

Fiye si mi, ki O si da mi lohun, ara mi ko lelẹ ninu aroye mi, emi si n pariwo

Nitori ohun ọta mi, nitori inilara eniyan buburu, nitori wọn mu ibi ba mi ati ni ibinu, wọn dẹkùn fun mi

Aya dun mi gidigidi ninu mi, ipaya iku si ṣubu lu mi

Ibẹru ati ìwárìrì wa si ara mi, ati ibẹru iku bo mi mọlẹ.

Emi si wi pe A! iba ṣe pe emi ni iyẹ-apa bi adaba! emi i ba fo lọ, emi a si simi

Kiyesi i, emi iba rin lọ si ọna jinjin rere, emi a si maa gbe ni aginju, selah! (Selah tumọ si Amin)

13 Dafidi, olólùfẹ́ àginjù, nigba ti ìrẹ̀wẹ̀sì ba a ti awọn eniyan ko si gba a gbọ, ti awọn ọta si ti pagbo yii ka, o wi pe “kani mo ni íyẹ-apa bii ti àdàbà, emi i ba fo lọ sinu aginju, nibẹ ni n ba simi.” Oye igba melo ni mo ti ro ohun kan naa! Bi mo ba lee gbe ibọn mi kuro lara ogiri, gbe apo ọdẹ, ki n si rin lo sinu aginju, ki n ma si pada wa si ile mọ. Mo ti beere lọwọ Oluwa bi mo ba lee ri ọjọ naa… Emi ko fe isin isinku rara. Mo ni, “Bi mo ba lee lọ sinu igbo nibikan, gbe 'blondie' atijo ti igi kan … ”Iyẹn ni ibọn mi, e ṣe gafara fun mi. Mo sọ eyi nitori iyawo mi ti o joko si ibẹ yẹn.

Ṣe o mọ arakunrin kan nihin ni o fun mi ni ibọn naa ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, mo ti pa ẹran igbẹ marun-din-ni ọgọta pẹlu rẹ, lai tàsé eyọkan, ọpọlọpọ awọn ẹran naa jẹ ọgọrun meje si ọgọrun mẹjọ yaadii si mi. Mo pe ibọn naa ni blondie, nitori iyawo mi jẹ brunette, o si wi pe mo n ronu nipa ibọn mi ju bi mo ṣe n ronu nipa oun lọ.

Nitori naa, maa fẹ gbe ibọn naa ti igi kan, n o si sọ pe, “Oluwa jẹ ki Josefu rii lọjọ kan,” n o fẹ gun ori iyẹ-apa ẹyẹ adaba ki n si fo lọ

Gẹlẹ bi o ti ri lakoko kan lori awọn oke nla kan ti mo n wo ẹyẹ idi kan ti mo rii ti o fo lọ (Ẹ mọ itan mi nipa rẹ). Mo sọ wi pe o “O dara lati wa nihin, Oluwa” Gẹgẹ bi Peteru ti sọ, “A lee kọ agọ mẹta,” sugbọn ni isalẹ oke naa, awọn alaisan ati awọn alailera n duro, awọn ti o ti sọnu ti wọn sii n ku lọ n duro. Nitori naa, ẹ jẹ ki a ṣe ohun ti a lee ṣe nigba ti o jẹ ọsan ati ni ọjọ kan, ohun kan yoo… iyẹ-apa Ẹye-Idi funfun kan yoo sọkalẹ. Oun yoo si ru wa lọ.

14 Wayi, ni Matthew 3:16, N o fẹ ka 16 ati 17

Nigba ti a si baptisi Jesu tan, O jade lẹsẹ kanna lati inu omi wa, si wo o, orun si silẹ fun un o si ri Ẹmi Ọlọ́run sọkalẹ bi adaba, o si ba le E

Si kiyesi i ohun kan lati ọrun wa n wi pe, Eyi ni ayanfẹ Ọmọ mi Ẹni ti inu mi dun si gidigidi. (Ni ọrọ miran, “Ninu Ẹni ti Inu mi dun lati maa gbe.)

15 Wayi, a fẹ sọrọ fun iseju diẹ lori ẹyẹ yii. Adaba jẹ ọkan lara awọn ẹyẹ ti mo fẹran julọ. Ati ni rironu nipa adaba, adaba nitootọ jẹ… ati ẹyẹle jẹ iru ẹyẹ kan naa. Ẹyẹle jẹ ẹyẹ ti nṣere laarin ilu. Mo ti ṣe iwadi lori wọn, wọn jẹ ẹbi kan naa. Ẹyẹle ati àdàbà jẹ ara ẹbi kan naa. Iwa awọn ẹyẹ wọnyii tayo pupọ.

Mo waasu nihin, ni awọn ọdun diẹ sẹyin, ni ipade agọ kan nibẹ pẹlu Arakunrin Moore lori Ọdọ-aguntan Ati Adaba. Mo lérò wipe gbogbo yin ranti iwaasu naa; ni bi adaba ṣe jẹ afińjú ẹyẹ ti a ni, ati bi ọdọ-agutan ṣe

jẹ ẹranko ti o ni iwa-tutu julọ ninu awọn ẹranko. Awọn méjèèjì jẹ ẹran ìrúbọ.

16 Bi eleyi ṣe jẹ afiwe ti o rẹwa nipa Jesu ti i ṣe Ọdọ-Agutan, ati ti Ọlọ́run jẹ Adaba. Adaba ko lee bà lori i ikooko, iwa-ẹda ikooko ko tọ. Adaba ko si lee ba lori aja, iwa-ẹda aja ko tọ. O jẹ ọdọ-agutan ti o lee ba le, nitori naa iwa ẹda awọn mejeeji ni lati ṣe rẹgi. Bi awa pẹlu ni lati yi pada lati iwa-ẹda ẹlẹṣẹ ti n bu ramuramu si ti ọdọ-agutan ti o tutu.

Ati pe njẹ iwọ kiyesi pe Adaba ni o dari Ọdọ-Agutan? Si kiyesi pe Ọdọ-Agutan jọwọ ohun gbogbo ti o ni fun Adaba. Si wo ibi ti Adaba dari Rẹ lọ: sí ìkàn-mọ-àgbélèbu fun ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo wa.

Wayi adaba… Bi Ọlọ́run ba fẹ ki ohun kan duro fun Ọmọ Rẹ, ẹranko to mọ ti o si ni iwa tutu julọ lori ilẹ aye, ẹda ti o' ngbe ori ilẹ, sugbọn nigba ti Ọlọ́run n fẹ ohun ti yoo duro fun Oun ni oju ọrun, o jẹ nipa ẹyẹ ti o tutu ti o si mọ julọ ti o wa loju ọrun-adaba.

17 Wayi, awọn adaba yatọ sira. Orisirisi adaba ni o wa. Lọpọ igba adaba eti-odo jẹ ẹyẹ alawọ eeru. Lẹyin naa a ni adaba olohun asọ̀fọ̀, a tun ni adaba irọlẹ. Adaba sònórà ti a ni ninu ile naa wa. O jẹ adaba alawọ eeru kekere, ẹyẹ kekere ti o ni awọn ila pupa lara iyẹ-apa rẹ. Orisirisi adaba ni o wa, awọn awọ wọn si yatọ sira. Bakan naa ni o ri pẹlu ẹyẹle.

Wayi o, adaba jẹ ẹyẹ ti a da ni ọna ti o sajeji pupọ nitori ti iwa ẹ̀dá rẹ ṕe o jẹ ẹyẹ ti ko lee jẹ ohunkohun ti o dọti. Ko tilẹ lee ṣe ni, nitori a ko daa bẹẹ

18 Wayi o, mo ti maa n sọrọ nipa adaba pe o jẹ ẹyẹ ti o jẹ ami Ọlọ́run ati igun ti o jẹ apẹẹrẹ alágàbàgebè. Igun lee joko lori oku ẹran, ki o si jẹ lati aarọ dalẹ, ki o si tun fo lọ si oko alikama ki o si jẹẹ pẹlu adaba. Sugbọn adaba lee jẹ alikama, sugbọn ko lee jẹ oku ẹran. Ṣe ẹ rii? Ko lee ṣe ni, inu rẹ ko lee gba. O si maa n ṣe mi ni kayeefi idi ti ko fi lee jẹẹ ẹyẹ sa a ni awọn mejeeji, ẹyẹ ni wọn. Sugbon eeṣe? Bi a ti ṣe ṣe ẹda wọn ni.

Bi o ṣe ri gẹlẹ pẹlu ojulowo Kristẹni ni yẹn. Kristẹni ọmọ ijọ aladamọ lee jẹ ohunkohun, sugbọn Kristẹni ti a ti tunbi ko lee jẹ alabapin pẹlu awọn ohun ti aye. Iṣẹda rẹ yatọ.

19 Mo ri i wi pe adaba ko ni òróòro. Òróòro ko si ninu rẹ, nitori pe ko nilo rẹ.

Nitori naa, bi o ṣe ri niyẹn pẹlu Kristẹni. Ko nilo ohun ikoro kankan, ṣe ẹ ri, nitori pe ounjẹ Ọlọ́run ni kan ni o lee jẹ. A ko si nilo ikoro lati mu ounjẹ rẹ dà, ifẹ ni yoo mu u da. Ikoro maa n sọ wi pe, “En … wọn tako mi. Sugbọn ifẹ maa n gbaa Ọrọ Ọlọrun.

Wayi o, Kristẹni ko ni orooro, nitori naa ko lee … o lodi si ẹdaa rẹ lati jẹ ohunkohun ti ko dara. Bi o ba jẹẹ, yoo pa ni. Sugbọn ko si ewu. Ko ni jẹẹ ni nitori pe ko ni inu ti yoo fi gba a.

20 Bi o si ti ri niyẹn pẹlu Kristẹni tootọ. Njẹ iwọ mọ pe a ko ka ẹṣẹ kẹsẹ si Kristẹni tòótọ́ lọ́rùn? Dafidi wi pe, “Ibukun ni fun ọkunrin naa ẹni ti Ọlọ́run ko ka ẹṣẹ si lọrun.” Nigba ti a ba wẹ o, ninu ẹjẹ Ọdọ-Agutan (ki i ṣe nipa igbagbọ-a-fi ẹnu jẹ, sugbọn ẹjẹ Ọdọ-Agutan tootọ); Ọlọ́run ko ka si ọ lọrun ohunkohun ti o ṣe, nitori pe o wa labẹ ẹjẹ naa, Oun ko si rii. Ẹjẹ ìrúbọ kan wa; Ọna kan ti O fi lee ri ọ ni ọ̀nà naa ti O fi ri ọ ṣaaju ìpilẹ̀ṣẹ̀ aye nigba ti O kọ orukọ rẹ sinu Iwe Iye Ọdọ-Agutan naa. Ohun ti O lee wo ko ju iyẹn lọ, nitori pe a ti ra ọ pada kuro ninu ohun gbogbo ti o ṣe, a ti wẹ ọ mọ ninu ẹjẹ Ọdọ-Aguntan. Nitori naa ko si òróòro kan ninu rẹ, ko si iwa baraku kan ti ko mọ ninu rẹ, nitori pee jẹ Ọdọ-Agutanti ṣe eyi; Ọlọ́run ko si lee ka ẹṣẹ si ọ lọrun nigba ti o ti ni ẹbọ ẹṣẹ kan nibẹ ti o n duro de ọ.

“O daa, o ni, ”Eyi fun mi ni aaye pupọ nigba naa, Arakunrin Branham, mo lee ṣe ohun ti o ba wu mi.“ Ohun ti o ba wu mi ni mo maa n ṣe. Nigba gbogbo. Sugbon nigba ti eniyan kan ba lee ri ohun ti Jesu ṣe fun oun, ti o si yi pada ti o lọ ṣe ohun ti o lodi si Kristi, o fihan wi pe, ẹni naa ko i tii gba Kristi.

21 Mo ni ìyàwó kan ti o joko lẹyin lọhun yẹn. Mo fi ọdun mẹ́ẹ̀wá juu lọ, ewú si kun ori rẹ bi tèmi. Idi ni pe obinrin naa duro laarin mi ati aye. Bi mo ba n lọ si oke-okun, n o … Ṣe eyi ko ni jẹ ẹbi ti a lee gbe inu rẹ, bi mo ba ko ẹbí jọ sayika mi, n o si wi pe: “Wo o ihin Ìyáàfin Branham, o yẹ ki o mọ pe Aya William Branham ni o jẹ. Iwọ ko gbọdọ ni ọkọ miiran nigba ti n ko ba si nile. Maṣe sẹju si ọkọ ọlọkọ,” ati gbogbo awọn nnkan wọnyii? “Maṣe ṣe panṣaga. Bi o ba da iru rẹ lásà, nigba ti mo ba pada de, emi yoo kọ ọ silẹ.”

Ati oun pẹlu yoo yi pada si mi yoo si wi pe, “Wayi baale mi, mo fẹ sọ nnkan kan fun yin pẹlu. Iwọ ko gbọdọ jade pẹlu obinrin miiran nigba ti o ba rin irinajo. Iwọ ko gbọdọ ṣe eyi tabi tọhun. Bi o ba daba rẹ, saa mọ wi pe bi o ba ti de, emi yoo kọ ọ silẹ.”

Wayi, njẹ iru ẹbi bẹẹ yoo jẹ ẹbi alayọ? Ṣe ẹ rii? Rara o! Bi mo ba nifẹ rẹ nitootọ… Mo tilẹ gbagbo pe bi mo ba ṣe aṣiṣe kan, ti mo yọ ṣubu, ti mo ṣe ohun kan ti ko dara, mo gbagbọ wi pe yoo dariji mi fun un, nitori pe o nifẹ mi. Bi oun pẹlu ba sẹ ohun ti ko dara, mo gbàgbọ́ wi pe n o dariji fun un dájúdájú, nitori pe mo ni fẹ

rẹ. Bi mo ba nifẹ rẹ bẹẹ, ko nilo aniyan kan. Bi o tilẹ jẹ wi pe yoo dariji mi, emi ki yoo ṣe ohunkohun ti yoo pa lara nitori ohunkohun. Emi yoo ni imọlara pee mi ni mo jẹbi julọ laye. Nko lee duro fun isẹju kan lati sọ fun nipa ohun ti mo ṣe, nitori mo ni ifẹ rẹ. O dara o, bi mo ba nifẹ rẹ pẹlu ifẹ ti eniyan bẹẹ, melomelo ni ifẹ Ọlọ́run mi fun Jesu Kristi yoo fi ju bẹẹ lọ to.

22 Bi mo tilẹ mu siga, emi ko mu u ri laye mi, sugbọn bi mo tilẹ ṣe bẹẹ, O lee dariji mi fun un. Mo gbàgbó pe yoo dariji mi. Bi mo ba mu ọti, emi ko mu un ri laye mi, mo gbagbọ pe Kristi yoo dariji mi fun un. Sùgbọ́n mo fẹran Rẹ púpọ̀púpọ̀ ju (ki Ọlọ́run ran mi lọwọ), emi ko fẹ ṣe ohunkohun bẹẹ; ṣe ẹ rii, nitori pe mo fẹran Rẹ. Awọn nnkan bẹẹ ti fi igbesi aye mi silẹ, nitori nigba ti O yi mi pada kuro ni igun ti o sọ mi di adaba eyi mu ìyípada ba mi, awọn ifẹ mi tẹlẹ ti fi mi silẹ. A ko si ka ẹṣẹ simi lọrun mọ nitori emi ko ni lọkan lati ṣee mọ, ko si ninu mi mọ lati ṣe nnkan bẹẹ.

23 Nnkan nla mìíràn nipa adaba yii ni pe, ẹyẹ ti o sajeji ni. Njẹ iwọ ri gbogbo awọn ẹyẹ…

Okan ninu awọn ẹyẹ ti mo fẹran ni òdèrékókò. Wayi, ẹyin ọmọkunrin, ẹ ma tabọn mọ awọn ẹyẹ òdèrékókò mi mọ o, ṣeẹ ri, nitori pe nko fẹ ki ẹ maa ṣe bẹẹ. Njẹ ẹ mọ bi àyà òdèrekókó mi ṣe di pupa? Ṣe ẹ mọ lọjọ kan Ọkunrin wa ti o n ku lọ lori igi-agbelebu, ko si ẹnikẹni ti o ran An lọwọ. Ọlọ́run pẹlu ti kọ Ọkunrin naa silẹ, O si n ku lọ. Èsó wa ni ọwọ ati ẹsẹ Rẹ, ẹ̀gbẹ́ Rẹ si n ṣẹ̀jẹ̀, ade ẹ̀gún si wa ni ori Rẹ, ẹjẹ bo O ni oju. Ẹyẹ kekere kan si n fo, ẹyẹ alawọ omi koko kan. O si wo Ọkunrin yii, o ro wi pe ìsẹ̀lẹ́ ti o buru julọ ti oun tii ri niyi. O si mọ wi pe ẹyẹ kekere ni oun, o si wo èsó nla ti awọn ara Romu ti kan mọ Ọ ni ọwọ̀, o si fo pẹlu iko ẹnu rẹ kekere, o si n gbiyanju lati fa awọn èṣó naa yọ. Nibẹ ni gbogbo aya rẹ ti kun fun ẹ̀jẹ̀, lati igba naa ni aya rẹ ti pupa. Nigba ti mo ba de lati pade Rẹ, mo fẹ ki ẹjẹ Rẹ jẹ aláàbò fun aya mi bi mo ti n gbiyanju lati gbeja Rẹ. Mo ni fẹ ẹyẹ òdèrékókò kekere ni.

24 Sugbọn, ṣe ẹ mọ, ẹyẹ òdèrékókò kekere ni lati wẹ; sugbọn, ṣe ẹ mọ adaba ko nilo iwẹ. Rara o, o ti ni òróró kan ninu rẹ ti o mu ki o mọ lati inu de ode. Ṣe ẹ mọ iyẹn? Adaba nii. Òróró adaba ni o nlo lati fọ ara rẹ. Njẹ o tii mu adaba kan lọwọ tabi ẹyẹle, tabi nnkan bẹẹ ti o gbọ oorun rẹ? Òróró ti o n mu jade lati inu rẹ ni. Ara rẹ ni ẹya ara kan ti n mu ororo jade ti o mu ki awọn iyẹ rẹ mọ lode nitoripe o n mọ lati inu de ode ni. Bẹẹni ẹyẹ àgbààyanu kekere kan ni o jẹ.

Wayi, mo mọ wi pe ẹ lee maa sọdẹ rẹ nihin, mo ro bẹẹ, ni Louisiana. Ẹ ma ṣe bẹẹ! o! Aa emi ko lee ṣe. Mo ro wi pe bi ebi ba npa mi, ko ni ni laburu ninu, sugbọn emi ko le ta ibọn lu ọkan ninu wọn bi mo ba n lati sẹ bẹẹ.

25 Àdàbà ni ohun nla kan ti o s'ajeji ninu ẹbi wa. Ni ọjọ kan nigba ti iya-baba mi … O wa lati oke nihin ni Kentucky, ni tosi agbegbe igbo-ọba Cherokee. O n ku lọ, obinrin kekere kan, o si n… Wọn ni o ni… mo ro wi pe wọn pe aisan ni aisan segede tabi nnkan bẹẹ. O si n ku lo. Baba-baba si kunlẹ lẹgbẹ ibusun rẹ, nigba ti Mama, Anti Birtie, Anti Halley, ati gbogbo wọn kunlẹ ni ayika ibusun naa. Baba kekere Charlie (ọmọkunrin ọlọdun mẹrin kekere kan), ti o jẹ ọmọ-ọwọ, Mama, ti o dagba julọ jẹ ọmọ ọdun mejila. O si ti ya irun rẹ dudu jade o wa lori ibusun o si bẹrẹ sii kọrin, “Apata Ayeraye, ṣe ibi Isadi mi,” nigba ti o n ku lọ. Baba-baba nigba naa ko tii di Kristẹni. Mo ṣe iribọmi fun un ni ọmọ ọdun ọgọrin o le meje, ni Orukọ Jesu Kristi, ni ẹsẹ odo ti Angẹli Oluwa ti farahan.

Sugbọn nigba ti o n kọ orin yii pẹlu ọwọ rẹ ti ko lagbara ti o naa si oke, adaba kan fo wa si ẹnu ọna, o wa o si ba le ori ibusun naa, o si n ṣe kuu kuu kuu, Ọlọ́run mu ọkan iya yii lọ sile.

26 Mo lọ si London, England pẹlu Arakunrin Jack ati Arakunrin Gordon Lindsay, obinrin kan si ti wa ti orukọ rẹ n jẹ Florence Nightingale (o sọ wi pe, mo ro wi pe, oun jẹ ọmọ-ọmọbinrin, tabi nkan Florence Nightingale ti o ti di oloogbe) o si ti kọ ọpọlọpọ lẹta si mi. O wa ni South Africa, ti arun jẹjẹrẹ n pa a lọ. O si ya aworan kan, ẹ o ti ri ninu iwe kan. Emi ko i ti i ri eniyan kan bi eleyi ri. Mo gbagbọ pe Arakunrin Jack wa pẹlu mi lọjọ naa. A lọ si ile oniwaasu kan; ile alufaa lẹyin ile ijọsin, nibi ti wọn ti gbe e wa.

Nigba ti a wa lode ni ori … nibi ti ọkọ-ofurufu ti sọkalẹ, wọn pe wa nikọọkan. Oun wa ninu aaye awọn alaisan nibẹ, wọn ti fi baalu gbe wa lati South Africa, nitori wọn mọ wi pe mo n bọ ni England ni akoko naa. Oniwasu gbee lọ si ile alufaa, a si pada lọ si ibẹ lati gbadura fun un.

27 Mo ti ri ọpọlọpọ alaisan ri, sugbọn apa rẹ dabi ẹni pe ko ju inchi kan lọ, agbari rẹ, ti o sun lẹra, o lee rii. Awọn ẹṣẹ rẹ, de ibi oke nihin nibi ibadi rẹ. Ko ju bi inchi meji lọ, eegun laasan ni. Ko si lee gbe apá rẹ soke, o ti rẹ ẹ pupọ, ju lati gbe ọwọ soke. O si n gbinyanju lati sọ nnkan, sugbọn ko ye mi ohun ti o n sọ. Nigba ti mo si ma gbo ohun ti o sọ mo gbagbọ pe lati ẹnu olutoju rẹ, o ni “Arakunrin Branham gbadura ki Ọlọ́run jẹ ki n ku.” Ko si lee… ko tilẹ fẹ wa laaye mọ. Mo si kiyesi; omije n san lati ẹgbẹ awọn eegun oju rẹ. Nibi ti o ti ri omije to lati sọkun n ko mọ ọ, nitori gbogbo isan rẹ ti gbẹ, o si wa ni ipo ti o buru jai. Ni wiwa ti mo wa lati gbadura fun alaisan, emi kom lee gbadura fun un lati ku. O si dabi ẹni pe ko lee ku, o sa wa nibẹ ni.

Mo kunlẹ pẹlu olusọ-aguntan yin ninu iyara naa lati gbadura. Nigba ti mo si kunlẹ lati gbadura, adaba kekere kan fo wọ si oju ferese, o bẹrẹ sii ṣe kuu kuu. Nigba ti mo pari adura, mo ro wi pe ẹyẹle ti o wa nibẹ nibi kan ni, ìkúùkú bo oju ọjọ lode, bi England ṣe maa n rií, erekusu British nibẹ. Adaba kekere naa dẹkun ati ma ṣe kuu kuu, o si fo lọ. Mo lọ mo si gbe ọwọ lee, mo si pe Orukọ Oluwa. Obinrin naa jẹ ẹniti o tobi, ti o lagbara, ti o si ni ilera loni-lori iye-apa adaba kan.

Adaba n fọ ara rẹ mọ lati inu wa. Kristẹni naa a maa ṣe bẹẹ, o maa n fọ ara rẹ mọ lati inu. Eyii mu arakan… Kristẹni ko ni òróòro lati dà ohunkohun nitori kii jẹ ohunkohun ti o dọti. Ṣe ẹ ri i? O n mọ́ lati inu de ode.

28 Wayi, wa kiyesi pe ẹyẹ yii… ọpọlọpọ nnkan ni mo ti kọ silẹ nihin, sugbọn aago yẹn n ba iṣẹ rẹ lọ. A lo ẹyẹ yii ninu Majẹmu Laelae fun irubọ, fun etutu ati iwẹnumọ. Ẹ jẹ ki a tọka nihin si ọkan ninu wọn ni Genesisi 15:9. Ẹ jẹ ki a ronu nipa ẹsẹ yii fun igba diẹ. Wayi, Abraham beere lọwọ Ọlọ́run nihin, bawo ni yoo ṣe ṣe eyi Ọlọ́run si n jẹ ki Ọrọ Rẹ di mimọ fun Abraham, O si n ṣee ni ọna ti o ṣajeji. Bẹrẹ pẹlu ni bi … Ẹ jẹ ki a bẹrẹ lati ẹsẹ kinni, emi ko fẹ kánjú lori eleyi.

> *Leyin nnkan wọnyi, Ọrọ Oluwa tọ Abraham wa ni ojuran…* [ṣẹ ẹ rii, Abraham jẹ wolii, nitori naa o ri awọn iran] *… Ma bẹru, Abraham: Emi ni asa rẹ ati … ere nla…* [Jehovah-Nissi, ṣe ẹ ri].
>
> *Abraham si wi pe Oluwa Ọlọ́run* [kiyesi 'O' gadagba, “Oluwa Ọlọ́run”, Elohimi. Ṣe ẹ rii?] *Oluwa Ọlọ́run* [ninu iran naa] *kinni Iwo yoo fi fun mi, emi sa a n lọ ni alailọmọ, Elieseri ti Damasku yii si ni ẹni ti o ni ile mi.*
>
> *Abraham si wi pe, wo o emi ni iwọ ko fi irú-ọmọ fun, si wo o ẹrú ti a bi ni ile mi ni yoo si jẹ àrólé.*
>
> *Si wo o Ọrọ Oluwa tọ o wa wi pe Eleyi ki yoo ṣe àrólé rẹ* [O ti fun ni iléri kan ṣe o mo. Ṣe ẹ rii, lójú ẹsẹ̀ nibẹ Abraham iba ti kuna, sugbon ileri naa ko duro lori káání, majẹmu naa ki i ṣe ti káání] *sugbọn ẹni ti yoo ti inu ara rẹ jade oun ni yoo ṣe àrólé rẹ.* (Oun si jẹ ẹni ọgọ́ọ̀rún ọdun nigba naa).
>
> *O si mu un jade wa si gbangba, o si wi pe, “Gboju wo oke ọrun nisisiyii, ki o si ka awọn irawọ bi iwọ ba lee ka wọn: o si wi fun un pe,” Bẹẹni iru-ọmọ rẹ yoo ri* (ọkunrin ti ko ni ọmọ, ti o si ti pe ọgọ́ọ̀rún ọdun bayi).
>
> *O si gba Oluwa gbọ; Oun si ka a si fun un ni ododo.*
>
> *O si wi fun un pe, Emi ni Oluwa ti o mu ọ jade lati Uri, ti Kaldea wa, lati fi ilẹ yii fun ọ lati jogun rẹ.*
>
> *O si wi fun un pe, woo… Oluwa…tabi, Oluwa … nipa bawo ni emi o fi mọ pe emi o jogun rẹ?*

Wa tẹti si eyi:

> *O si wi fun un pe, Mu ẹgbọrọ màálu ọlọdun mẹta fun Mi wa, ati abo ewurẹ ọlọdun mẹta* (kiyesi awọn mẹta naa bayi)*, ẹran ọlọdun mẹta, ati agbo ọlọdun mẹta ati oriri kan ati ọmọ ẹyẹlẹ kan* (mejeeji jẹ bakan naa)

A lo o fun irubọ ti o n ṣe àkọ́wo ojiji Jesu.

29 A se majẹmu naa … Sẹ ẹ mọ bi o ṣe la wọn si meji, ati bi eyi….

Tabi ni igba atijọ, ti wọn n ṣe majẹmu, wọn yoo mu wọn yoo kọ adehun naa silẹ. Wọn yoo pa ẹranko kan, wọn a si duro ni aarin rẹ, wọn a ya iwe majẹmu naa si meji. Ẹnikan yoo mu apa kan….

Bi awọn alágbàfọ̀ ara China ti maa n ṣe. Ara China yii nihin, ko lee kọ ede Òyìnbó, nitori naa yoo kọ si ibẹ yoo fa iwe kan ya, yoo wa fun ọ ni abala kan rẹ. Ṣe ẹ ranti igba ti awọn alágbàfọ̀ ara China maa nṣe iyẹn. Lati lee gba asọ ti o fun un lati fọ, awọn iwe ti o ya si mejeji gbọdọ fi ẹnu ko ara wọn rẹ́gírẹ́gí ki o to fun ọ ni asọ rẹ. Ṣe ẹ rii, o o lee tanjẹ, nitori abala iwe ti o ya kan wa ni ọwọ rẹ. O lee fun ni orukọ olorukọ, sugbọn o ko lee tun bébà naa ya. Ṣe o ri i? O ni lati jẹ bébà akọkọ ti o ya.

Bakan naa ni wọn ṣe maa n sẹẹ ni ila oorun agbaye nigba naa, nigba pípẹ́… tabi nigba atijọ ni Ila Oorun àgbáyé. Wọn yoo pa ẹran kan, wọn yo o si duro ni agbede-meji rẹ, wọn yoo ya awọ-ewurẹ naa si meji, ẹnikan yoo mu ọkan… Nigba ti o ba si fi ẹsẹ majẹmu naa mulẹ, wọn yoo mu abala awọ mejeeji ti a ya wa, wọn si n lati fi ẹnu-ko-ẹnu ki wọn baramu rẹ́gírẹ́gi.

30 Wayi, ohun ti Ọlọ́run n fi i han Abraham nihin ni yii: Awọn ẹbọ yii n sọrọ nipa Kristi, ati bi Ọlọ́run ṣe mu Jesu lọ si Kalfari ti O si fa A ya si meji, ti O si gba ara naa lọ si oke ọrun ti O si ran Ẹmi Rẹ pada wa si ori wa, ki Ẹmi ti o wa lori Rẹ lee wa sori rẹ ki o si ba Ara naa mu ki a lee jẹ Iyawo Kristi ni opin ọjọ. Ṣe ẹ rii? Bi o ṣe ri gelẹ niyẹn. Ṣe ẹ rii?

Sugbọn bi Ọrọ Ọlọ́run ṣe n lati wa ba Ọrọ Ọlọrun, gẹgẹ bii iru ẹya-ara-ti-o-kere julọ ti eniyan. Ṣe ẹ mọ, nigba, ti a n fẹ bi wa, kii ṣe ẹya-ara-ti-o-kere-julọ ti eniyan, ati ti aja, ati ti ẹlẹdẹ. Rara o-ti-o. Gbogbo rẹ jẹ ti eniyan. Bi ara Kristi naa ṣe jẹ niyẹn, gbogbo rẹ jẹ kiki Ọrọ Ọlọ́run. Ki i ṣe ara Rẹ kan, ati awọn àsà kan ti a fi kun un, rara o, gbogbo rẹ jẹ ara Kristi.

Wayi a ri wi pe Ọlọ́run lo oriri ati ọmọ ẹyẹle, nitori pe wọn jẹ ara ẹbi kan naa. Wayi, iwọ ni gbogbo igba…

31 Wa kiyesi (N o tọka si awọn Iwe Mimọ wọnyi) Leviticus 12, ati ẹsẹ kẹfa. A ri nihin ilana bi a ti n ṣe iwẹnumọ fun obinrin. Bi obinrin ba bi ọmọ, o nilati duro. Bi o ba jẹ ọmọkunrin, o nilati duro fun ọjọ mẹtalelọgbọn ki o to lee wọ inu ijọ eniyaṇ Ọlọ́run pẹlu awọn adaba fun iwẹnumọ. Bi o ba jẹ ọmọbinrin, o nilati duro fun ọjọ mẹrin-din-ni-ọgọrun ki o to lee wọ inu ajọ awọn eniyan mimọ.

Nihin a rii ni ẹsẹ kẹfa.

Nigba ti ọjọ ìwẹ̀nùmọ́ rẹ ba pe fun ọmọkunrin, tabi fun ọmọbinrin, ki o mu ọdọ-agutan ọlọdun kan wa fun ẹbọ sisun ati ẹyẹle, tabi adaba, fun ẹbọ ẹṣẹ tọ alufaa wa si ẹnu-ọna agọ ajọ.

Ṣe ẹ rii, obinrin naa ko i ti lee wọle wa nitori pe ọjọ iwẹnumọ rẹ ko i tii pe, sugbọn o lee mu eleyi wa fun alufaa ni ẹnu ọna agọ, fun ẹbọ ẹṣẹ rẹ. Ṣe ẹ rii, yala oriri kan tabi ọmọ ẹyẹle kan. Wọ njẹ ara ẹbi kan naa.

32 Wayi a lo fun awọn etutu, ati ninu etutu fun ẹṣẹ, adaba kan. Tabi fun ẹtẹ ti i ṣe apẹẹrẹ ẹṣẹ, iwọ yoo mu adaba meji wa. A o fa ori ọkan tu, a o wa da ori rẹ kodò, yoo wa tu ẹjẹ rẹ sori ekeji rẹ, ekeji ni a o tu silẹ lọ. Nigba ti ekeji yii ba n fo lọ, yoo maa fi ẹjẹ ekeji rẹ wọn ilẹ lọ, ẹjẹ naa yoo maa ke pe Ọlọ́run pe, "Mimọ! Mimọ! Mimọ si Oluwa Ọlọ́run!"

Njẹ iwo lee ri ekeji ti n ku lọ, Jesu Kristi? A pa A a si wọn ejẹ Rẹ le wa lori ki a le lọ ni ominira, ti a o maa kigbe sita pe, "Mimo! Mimọ! Mimọ! si Oluwa. Iru awọn apẹẹrẹ ti o rẹwa niyi. Inu mi iba dun bi ohun mi ko ba ha.

33 Eyi ṣe apẹẹrẹ Ẹmi Mimọ nla gẹgẹ bi a ṣe ka ninu Iwe Ifihan 3:16, adaba yii ni a lo fun awọn ami.

A fun Noah ni ami kan, gẹgẹ bi arakunrin kan ti kọrin nipa rẹ lẹẹkan. Inu Ọlọ́run bajẹ, ko si si ohun ti yoo da ibinu Rẹ duro, nitori O wi pe, "Ọjọ ti o ba jẹ ninu rẹ ni iwọ yoo ku." Noah si ti ri oju-rere lọdọ Ọlọ́run, o si ti kan ọkọ ni ibamu pẹlu kikan naa… mo fẹ sọ wipe nibamu pẹlu awọn itọni ti Ọlọ́run ti fi fun un. O si ti lefo lori omi.

Mo lee ro wo ohun ti o sẹlẹ ni awọn ọ̀jọ wọni nigba ti n wọn wi pe, "Ọkunrin arugbo yii ti o wa lori oke yii, ọkunrin alákatakítí kan ti o n kan ọkọ kan, ti o n kan ọkọ kan ti o n sọ pe ojo yoo rọ, ojo ko si rọ ri"

Sugbọn Noah sọ wi pe "Ojo yoo rọ, lọnakọna"

Ati lẹyin naa, mo mọ ọjọ ti o wọ inu ọkọ, mo ro wi pe… emi ko lee ranti ọjọ ti o jẹ. Mo gbagbo pe ojẹ ọjọ ketadinlogun Osu Karun, Noah wọ inu Ọkọ naa, Ọlọ́run si ti ilẹkun ọkọ naa.

Awọn ikuuku bẹrẹ sii ko ara jọ, ojo si bẹrẹ sii rọ, awọn salanga bẹrẹ sii kun, awọn orisun ibu ya, awọn odo kekeke bẹrẹ sii tu omi wọn jade. Nikẹyin awọn eniyan wọ inu ile, wọn gun oke ile lọ. Ọkọ na wa nilẹ nibẹ.

Lẹyin igba diẹ, nigba ti omi bẹrẹ si i kun yii ka, ọkọ naa bẹrẹ si i gbera lọ soke soke soke sii. Awọn eniyan nkan ilẹkun ọkọ naa wọn si n pariwo, sugbọn ko ṣe wọn ni anfani kankan, Noah ko lee si ilẹkun ọkọ naa. Ọlọ́run ni o ti ilẹkun naa, Ọlọ́run nikan si ni o lee si ilẹkun ọkọ naa.

Bakan naa ni o ri pẹlu ọkọ wa Jesu Kristi. Ọlọ́run si ilẹkun ọkọ naa fun wa ni Kalfari bẹẹ gẹgẹ bi O ṣe si ilẹkun naa, o daju pe yoo si ti i.

34 O si lefo, ati bẹẹ ati bẹẹ lọ, boya o to ibusọ kan si isalẹ ilẹ aye nigba ti ile aye n gb'okiti kuro ni ona rẹ … kuro ni bi o ṣe maa n yi, ati yi kaakiri, ati awọn ẹya rẹ ati awọn igi ati lori awọn oke nla ati bẹẹ bẹẹ lọ, ti o n ti sihin sọhun fun ogoji ọsan ati ogoji oru.

Ati nigba ti awọn atẹgun bẹrẹ sii dawọ duro…

Ibinu Ọlọ́run buru jai. Ifẹ Rẹ mọ o si jẹ tọrun; ibinu Rẹ si jẹ … ibinu Rẹ jẹ ti ọrun bi ti ifẹ Rẹ, nitori a ni lati mu idajọ wa nitori pe onidajo ni. A fun ni lofin ni, ati ofin ti ko ni ijiya kii ṣe ofin. Nitori naa ijiya gbudọ wa pẹlu

ofin. Ti o ba re ofin Ọlọ́run kọja, nigba naa ni o ni lati gba ijiya naa.

35 Wayi, a kiyesi pe lẹyin ti Noah ti lefo lori omi loke nibẹ, ko si iyemeji o ti ni lati ni aisan ọkọ oju omi lati inu ariwo omi riru omi, ati ibinu Ọlọ́run ti n tẹ, ti n rún ati awọn igbe ati bẹẹ bẹẹ lọ, nigba naa ni gbogbo rẹ bẹrẹ sii walẹ. Ohun kan ko sẹlẹ mọ. Ọpọlọpọ ọjọ kọja, ohun kan ko sẹlẹ. Boya ounjẹ fun awọn ẹranko ati bẹẹ bẹẹ lọ ti bẹrẹ sii tan, ko si si ohun ti o sẹlẹ. Nitori naa Noah ro wi pe “O n roo… Emi ko lee ri ita.”

A kan ọkọ naa, bi o ba wa ninu rẹ, iferese kan ni o ni, o si wa ni oke ọkọ naa. O ko lee wo ẹ̀gbẹ́, o ko si lee wo ọnakọna bikoṣe taara loke. Bi Ọkọ tiwa naa, Jesu Kristi, ti ri niyẹn. O ko lee wo ẹni ti o wa lẹgbẹ rẹ, o ko lee wo ohunkohun bikoṣe Kristi nigba ti o ba wa ninu Ọkọ naa nitori pe ilẹkun kan ni o ni, Oun si ni ilẹkun naa ti a sọ ọrọ rẹ ni owurọ yii. O ni lati maa wo oke ni, “Nitori ẹni ti o ba fi ọwọ rẹ le ohun elo itulẹ ti o si wo ẹyin ko yẹ lati tulẹ.”

36 Wayi, gẹgẹ bii ninu ọkọ yii, Noah lee ri imọlẹ tabi boya oòrùn, sugbọn ibi ti o wa jẹ kayeefi fun un. Ọkọ naa si n lefoo, o lee gbọ awọn igbi-omi ti o n kolu ẹgbẹ ọkọ, sugbọn o ni wi pe oun ti lo ọjọ pupọ, dajudaju omi naa ti n fa lakoko naa. Nitori naa o lọ fun ẹyẹ kan ti ko ṣe e gbẹkẹle, ẹlẹtan, o si dan an wo o si ran jade. O je igun, igun naa ko si pada sinu ọkọ mọ lae, nitori pe o ri igbadun lode nibẹ, ni ita ọkọ Ọlọ́run. O n fo lati ori oku kan de ekeji, ti o n je oku ẹran, ẹran onidin ti o n lefo lori omi; o si ni itẹlọrun patapata.

37 Nitori naa lẹyin ọpọlọpọ ọjọ, o gbiyanju lẹẹkan sii, nitori o mo…. Ko fẹ gbe ẹsẹ sinu irunu Ọlọ́run. O wa si adaba silẹ. Iwa ẹda adaba si yatọ si … ki i ṣe Igun, bẹẹ ni ki i ṣe ẹlẹdẹ, ohun ti o ba mọ ni o lee jẹ awọn ohun ti ko ni abawọn. Ati nigba ti o rii wi pe oun ko ni ohun ti oun lee gbe ẹsẹ le, o pada sinu ọkọ naa. Noah wa wi pe, “O da o, ẹkun omi si wa sibẹ.”

O tun duro fun ọpọlọpọ ọjọ, o tun wa ran jade; gẹgẹ bi adura rẹ, “Ah Iwọ Ọlọ́run n jẹ a ti tẹ irunu Rẹ lọrun?” N jẹ irunu Rẹ ti dopin, Oluwa? Ṣẹ o ti pari? O wa sọ wi pe, “Wayi, bi mo ba ran an jade lakoko yii, o lee ma pada mo bi ẹkun omi ba ti gbẹ, o lee duro.” Sugbọn o ran an jade, pẹlu adura nigbati o si jade pẹlu idari Ọlọ́run, o ja ewe igi tutu kekere kan, o si fo pada, o si fi iko lu oju ferese ọkọ lẹẹkan sii.

Ọlọ́run lo adaba naa gẹgẹ bii ami kan. O pada wa o n wi pe ẹkun omi ti dopin, lẹyin naa ni Ọlọ́run si ilẹkun ọkọ naa, wọn si jade. Eyi ni Genesis 8:8.

38 A tun lo o ni Matthew 3:16, lẹkan sii nigba ti irunu Ọlọ́run wa lori ilẹ aye. Ti ko si si ọna mọ, ni igba ti ilẹ su julọ, ni ọganjọ oru, awọn ijọ ti da oju gbogbo nnkan ru to bẹẹ ti ko si ọna lati jade kuro ninu rẹ. Awọn olukọni eke si wa, orisirisi nnkan ni n jade, ọpọlọpọ ifi-ẹnu-jẹwọ n dide, Ọlọ́run wa lo adaba lẹẹkan sii. O tẹ Ẹ lọrun, Ọmọ Rẹ Jesu ti tẹ Ẹ lọrun to bẹẹ, ti O fi fi I han.

Wayi, wọn ko lee gbagbọ pe ọmọ ọwọ yii ti a bi nibẹ ni ibujẹ-ẹran, ki awọn mejeeji ti wọn ro wi pe wọn jẹ Baba ati Iya Rẹ to ṣe igbeyawo, wọn ko lee ro wi pe Ọlọ́run yoo lo ohun tii o jọ bẹẹ. A wa ni lati fi I han fun aye. Ati ni ọjọ naa ni ẹṣe odo naa nigba ti o rin wa lati fi ara Rẹ han wi pe Oun ni Olubori-isẹ Ọlọ́run ti mo sọrọ nipa rẹ láàárò yi, nigba ti O ṣe igbọran lati rin lọ sinu omi…

39 Wayi, bi o ba kiyesi nibẹ, ẹko nla kan wa nibẹ. Johannu jẹ ẹni ti o tobi julọ lori liẹ aye, ni akoko naa. Jesu sọ wi pe ko si ẹni ti a bi ninu obinrin ti o tobi to Johannu, titi di akoko naa. Oun si jẹ Wolii. Ṣe o gba iyẹn gbọ? Wayi, ranti, bi Ọrọ Ọlọ́run yoo ba tọ ẹnikẹni wa lori ilẹ, yoo jẹ nipa wolii. Bi ọna Ọlọ́run ṣe maa n ri niyẹn. Njẹ iwọ gbagbọ pe Jesu jẹ Ọrọ Ọlọ́run ti a fihan ninu ara? Nitori naa, ọna kan soso ni a fi lee fi Jesu han - ki i ṣe nipa awọn alufaa.

Ko lọ ki O sọ pe, “Caiaphas, njẹ iwọ yoo fi Mi han?” Bi O ba sẹ bẹẹ O ṣe asiṣe ti Dafidi ṣe ninu ẹkọ wa ni ijelo; sẹ ẹ rii, bi O ba lọ si ile-ijọsin ti O sọ pe, “Ṣe ẹ o fi Mi han?”

40 Sa a kiyesi nigba ti a bi I, paapaa. Nigba ti a bi I, a bi ni abẹ ojiji ijọ. Ati boya wọn lu aago ati ohun gbogbo, sugbọn o jẹ awọn olusọ-aguntan ati awọn amoye ni wọn da A mọ. Ṣe ẹ rii?

Oun si niyi ti O ti sẹtan fun iṣẹ-iriju iwaasu Rẹ. Bi O ba jẹ Ọrọ Ọlọ́run… Nibamu pẹlu ilana Ọlọ́run nla, Ọrọ Ọlọ́run lee… “Oluwa Ọlọ́run ki yoo ṣe ohunkohun ayaafi ti O ba fihan fun awọn iranṣẹ Rẹ, awọn wolii.”

Ilana Re ni eyi, ni gbogbo igba, o nilati ri bẹẹ. Nigba ti a si awọn edidi mejeeje, nigba ti a ṣi ohunkohun miran, isẹlẹ pataki ti o ba n lati ṣẹlẹ ni ori-ilẹ aye, Ọlọ́run Maa n fi han fun awọn wolii Rẹ.

Johannu jẹ wolii naa, nitori o n sọ tẹlẹ pe yo O wa.

Nigba naa ni ibi ẹgbẹ oke kan lojọ kan … nigba ti itakurọsọ kan n lọ lọwọ, awọn ẹgbẹ alufaa wa ni iduro ni itosi. Wọn si wi pe, “N jẹ o fẹ sọ fun mi pe iwọ jẹ wolii ti o si duro nibẹ ninu ẹrọfọ naa (ki i ṣe ninu ijọ nitori wọn ki yoo gbaa) ti o duro ninu ẹrọfọ ti o si n sọ fun mi pe wakati naa n bọ nigba ti Jehovah nla, ti o yan awọn ẹbo yii, nigba ti Jehovah nla ti o Kọ tẹmpili yii, ti o wọ inu rẹ gẹgẹ bi Ọwọn Ina pe, ”:ọjọ naa n bọ nigba ti a o

mu ẹbọ ojoojumọ kuro?“

O si wi pe, “Ọkunrin kan yoo wa, O si wa laarin yin bayi, nibi kan nita nibẹ, Oun yoo si mu ẹṣẹ kuro.” Alufaa korira Rẹ pupọ.

41 Johannu woke. Wayi, kinni O jẹ? Wolii naa! Ọrọ Ọlọ́run niyi, nihin ni Ọrọ Ọlọ́run n bọ wa taara sọdọ wolii, taara sinu odo. Johannu wi pe; “Wo O, Ọdọ-Agutan Ọlọ́run ti N ko ẹṣẹ aye lọ. Nibẹ ni O wa, Oun ni yẹn.” Jesu ko sọ ẹyọ ọrọ kan, O rin lọ taara sinu odo. Mo si lee ri I nibẹ, ti O duro ni inu odo naa (ronu nipa ere-ori-itage), awọn meji ninu awọn ti o ga julọ ti wọn tii wa si aye ri. Ọlọrun Ọrọ naa, ati wolii Rẹ.

Kiyesi i, Ọrọ Ọlọ́run tọ wolii wa, ni saa oore-ọfẹ yii, ninu odo. Mo ro wi pe o ye ki o ti ye ọ. Ninu odo! Ifihan akọkọ ti Ọrọ Ọlọ́run jade lati inu odo. Njẹ o ri ibi ti Iyawo Kristi ti bẹrẹ ẹ Ọrọ Ọlọ́run ti imọlẹ irọlẹ yii? Ninu odo! Ọrọ Ọlọ́run, Ọrọ Ọlọ́run tootọ naa ti ko dapọ mọ ẹkọkẹkọ, sugbọn ti o tọ wolii wa ninu omi, lẹba odo.

42 Kiyesi! Njẹ o lee ro o wo wi pe oju Ọrọ Ọlọ́run ati oju wolii pade ninu odo? A a, eyi ti pọju fun mi! Nibẹ ni wolii duro, nibẹ ni Ọrọ Ọlọ́run duro ti wọn n wo ara wọn. Wolii si wi pe, “Mo nilo ki O baptisi Mi, eeṣe ti O fi tọ mi wa?”

Ọrọ Ọlọ́run si wi pe… o ni lati ri bẹẹ. Jẹ ki n mu ere-ori-itage kan wa nihin:

Johannu, wolii ni o jẹ, o mọ ọrọ Ọlọ́run (Ṣe ẹ rii?). O da Mi mọ, o mọ Ẹni ti Mo jẹ.

“Johannu sọ wi pe, ”Mo nilo pe ki O baptisi mi.“

Jesu sọ wi pe, “Gba eyi laaye ki o ri bẹẹ. Bẹẹ gẹlẹ ni o ri, o ni lo Ki N baptisi rẹ. Sugbọn ranti, Johannu, nitori pe o jẹ wolii, o yẹ fun wa, o tọ fun wa, gẹgẹ bii Ọrọ Ọlọ́run ati wolii ki a mu gbogbo Ọrọ Ọlọ́run sẹ. Nitori, Johannu (eyi ni ifihan naa bayi), Johannu, o mọ Ẹni ti Mo jẹ. Emi ni ẹbọ naa. Ati ni ibamu pẹlu Ọrọ Ọlọ́run, a nilati fọ ẹbọ naa ki a to mu u jade fun irubọ.” Sẹ bẹẹ ni? Ọrọ Ọlọ́run… Ọdọ agutan ni a fọ lẹyin naa a mu u wa fun irubọ. Emi si ni Ọdọ-Agutan naa. A si ni lati fọ Mi ki a to lee mu Mi jade wa fun aye fun irubọ. Gbaa laaye ki o ri bẹẹ, Johannu, nitori o yẹ fun wa gẹgẹ bii Ọrọ Ọlọ́run ati wolii lapapọ.“

43 O ti daa o, ko lee si asiṣe Kankan. Wayi, ọkọọkan awọn nnkan wọnyii….

Wayi, woo, kani ki i ṣe igbekalẹ naa, Johannu iba ri bi eyikeyi ninu wa, iba sọ wi pe, “Bẹẹ ni, Mo mọ ẹniti Ẹ jẹ, Oluwa.”

O dara. O wi pe tẹti simi ni isẹju kan, “Emi ni Ọrọ Ọlọ́run. 'Eniyan ko le wa laaye nipa akara nikan, bikọṣe nipa gbogbo Ọrọ Ọlọ́run.' Eefa kuna lori ẹyọ Ọrọ Ọlọ́run kan, sugbọn iwọ ni lati gba gbogbo Ọrọ Ọlọ́run. Emi ni ẹbọ naa a si ni lati fọ Mi ki a to fi Mi rubọ. Sugbọn ohun ti o sọ Johannu, otitọ ni.”

Johannu ti o jẹ wolii, ti o si mọ pe a n lati mu Ọrọ Ọlọ́run ṣẹ, o gba laaye o si baptisi Rẹ. Ati nigba ti O jade kuro ninu odo, bẹẹ ni iṣẹ wa lati orun lori iyẹ adaba kan, “Eyi ni ayanfẹ Ọmọ Mi.” O ran iṣẹ irapada ti oore-ọfẹ lori awọn iyẹ adaba kan, ti o n fo wa silẹ lati awọn ọrun. “Alaafia lori ilẹ-aye, ifẹ-inurere si awọn eniyan.” Ẹbọ naa ti sẹtan lakoko naa. Ti a gbe dide, ti a bọ O, Iṣẹ-Iriju-Iwaasu Rẹ ti sẹtan, Ọrọ Ọlọ́run kan ti yoo ra gbogbo aye pada, “O ti tan!”

44 A lo adaba ninu Bibeli gẹgẹ bii ami alaafia, awọn orilẹ-ede si n lo gẹgẹ bi ami alaafia. A ni awọn orilẹ-ede… Ẹyẹ Idi ni o duro fun orilẹ-ede wa, awọn ẹyẹ miiran si wa ti o duro fun awọn orilẹ-ede miiran. Roomu ni ẹyẹ idi, Germany ni ẹyẹ idi; ọpọlọpọ wọn, awọn ẹyẹ nla nla ti oju ọrun. Sugbọn ninu gbogbo wọn, adaba duro fun alaafia ni gbogbo orilẹ-ede, O jẹ ohun agbanla-aye kan.

Gẹgẹ bi Green ti sọ ni alẹ ọjọ kan, Arakunrin Pearry Green ti sọ, “Ami ijọwọ-ara-ẹni-silẹ ni 'ki a gbe ọwọ soke,' Orilẹ-ede k'orilẹ-ede, gbigbe ọwọ soke, ami ijọwọ-ara-ẹni ni.” O wipe, “Nigba ti O ba n kọ orin, gbe ọwọ rẹ soke, pe mo jọwọ ohun gbogbo patapata.”

Adaba si jẹ ami alaafia ni gbogbo orilẹ-ede. Eeṣẹ ti o fi ri bẹẹ? Nitori pe o ni iwa pẹlẹ ati nitori pe ko lee pa ohunkohun lara. Idi niyi ti o fi duro fun alaafia.

45 Ohun kan miiran nipa adaba, o jẹ ẹyẹ ti o fẹran ile. O maa n fẹ lati wa ni ile.

Ohun kan miiran nipa rẹ ni pe, o maa n jẹ olootọ si ekeji rẹ. Abo ati akọ adaba kii fi ara wọn silẹ. Abo maa n wa akọ ri lakoko iloyun ni. Woo, eyi ba iwa ẹda awọn ẹda Ọlọ́run mu. Idi niyi ti O fi da Eefa gẹgẹ bi ohun-a-mu jade lati inu ọkunrin. Ṣe ẹ rii, bi a ba daa bi gbogbo awọn abo miiran, nigba ti akoko iloyun ba de, iba wa akọ rẹ kan, sugbọn o le ri akọ rẹ nigba-ki-igba. Ṣẹ ẹ rii. Bi o ṣe ri niyẹn, bi o ṣe jẹ niyẹn. Mo fẹ … A ko fẹ lọ si inu eleyi nitori pe mo ni ẹkọ yii ninu “Igbeyawo ati Ikora-ẹni-silẹ” ati awọn iwaasu miiran bẹẹ. Ati bi o ti

…. Sibẹ obinrin naa jẹ ẹni ọla, o si n mu iwa rere naa wa, ẹ si mọ bi mo ti waasu nipa rẹ ni alẹ ijelo. O da a, kiyesi, o ni ojuṣe nla.

Sugbọn adaba maa n jẹ olootọ si ekeji rẹ. Ni gbogbo igba! Kii fi abo rẹ silẹ.

46 Jẹ ki n danu duro nihin fun iseju kan lati sọ eyi: iyawo tootọ ti o jẹ apẹẹrẹ abo adaba, maa n jẹ olooto si akọ rẹ pẹlu. Ki yoo gba ẹkọ adamọ kan wọle, ẹkọkekọ ijo aladamọ kan, ohunkohun ti o jẹ ti aye. Yoo jẹ olootọ si ọkọ rẹ, Ọrọ Ọlọ́run. Nigba gbogbo ni yoo jẹ olootọ.

Ati nipa iwa ti ifẹ si ile yii, nipa iwa níní ifẹ ile, a ti lo o pẹlu aṣeyọri gẹgẹ bi ẹyẹle ti n jiṣẹ. Nitori ti o nifẹ ile, bi o ba ṣii silẹ nibi-ki-bi yoo maa pade si ile ni. Yoo pada sile.

A o fẹ lati tẹnumọ iyẹn fun igba diẹ, ẹyin Kristẹni yoo mọ ohun ti mo ni lọkan. O maa n wa ọna rẹ pada sile ni, nitori naa a ti maa n lo gẹgẹ bi ẹyẹ ti n jiṣẹ. A maa n lo lakoko ogun, nigba atijọ. Wọn si n lo wọn sibẹ, awọn adaba ti n jisẹ lati jẹ iṣẹ. Nitori naa ẹ ri bayi pe, Ọlọ́run ati eniyan n lo adaba gẹgẹ bi iranṣẹ; adaba jẹ iranṣẹ. Iranṣẹ ni o jẹ fun Noah, lati sọ fun Noah pe “alaafia ti pada sori ilẹ aye.” Ọlọ́run lo o lati jẹri gbe e pe eyi ni Ọmọ ti Oun, ẹbọ lati mu alaafia wa sori ilẹ aye ati ifẹ-inu-rere si awọn eniyan. A lo gẹgẹ bi iranṣẹ.

47 Nihin, mo ni itan kekere kan lọkan, ti mo ka lati inu iwe kan. Wayi, n ko fẹ sọ wi pe eyi jẹ ootọ, o lee jẹ bẹẹ, Nipari Ogun Agbaye Akọkọ. Eyi ko da mi loju saka bayi; bi iwọ ko bati kaa, nigba naa mo kuna. Boya mo ka a ninu iwe kan ni… o jẹ ọpọlọpọ ọdun sẹyin. Sugbọn, o daju … ohun ere ori-itage ti o sẹlẹ ni.

Ibọn alagbara awọn Germany n rọ bi ojo lori awọn ọmọ-ogun America ti wọn wa ninu koto kan. Ẹyin ti ẹ ti jẹ soja ri, mo ro pe ẹ mọ bi soja ṣe maa n gbiyanju lati ri iroyin kan gba nibi kan niyẹn: A si ti de wọn mọlẹ, ohun ija ogun kekere ni o si ku fun wọn. Awọn ọmo-ogun Germany sii n rọ bọ, ọpọlọpọ ẹgbẹ ọmọ ogun nla si n wọ bọ lati ibi gbogbo. Awọn ọmọ ogun America si mọ wi pe, ayaafi ti iranlọwọ ba wa fun awọn, pe laipẹ gbogbo awọn ni a o pa danu, wọn ni lati ku ni. Awọn ara Germany si n ro bọ lati oke, wọn si n wo ọrun wọn, ti wọn n bọ wa ba wọn bẹẹ.

48 Ọkan ninu wọn wa ranti pe oun ni ẹyẹle kekere kan. O si mọ wi pe ẹyele yii, bi o ba lee jade, yoo lee lọ jisẹ ni ibudo awọn ologun wọn. Nitori naa wọn joko wọn si kọ iwe kekere kan, “A ti ka wa mọ ni ibi bayibayi, ni agbegbe bayibayi. Ohun ija ogun wa si ti tan. Ni wakati diẹ si, a nilati tuuba, ni tabi ki wọn pa wa ni ipakupa.” Wọn si so eyi… wọn de e mọ ẹsẹ adaba kekere yii, wọn si tuu silẹ.

Wayi, ẹyẹ ti o ni fẹ ile ni, nitori naa kinni o wa sẹ? O wa gbera lati pada sile fun… lati ri abo rẹ. Aaro abo rẹ ti n sọ ọ tẹlẹ, o ni lati pada sile.

49 Bi ẹyẹ yi i si ti fo soke, awọn ara Germany ti ri ohun ti o sẹlẹ, okan ninu wọn ta ibọn ọta ibọn kekere kan mọ ọn, eyi kán ọkan ninu ẹsẹ rẹ, ọta ibọn miiran ya ẹran ara rẹ ni bi apa ẹyin rẹ, ọta miiran tun fun ni ipalara ni ibi gbogbo aya rẹ. Ọkan ninu iye rẹ ti ni ipalara, ẹyin iyẹ yii ti kan, o ni lati fi ẹgbẹ kan maa fo lọ. Sugbọn ẹyẹ yii tẹsiwaju o n gun oke lọ, o si de ibudo nigbẹyin gbẹyin. Pẹlu bi a ti pa ẹyẹ yii lara to, ti a ṣéélẹ̀ṣe, ti a fa a ya, o ṣubu sinu ibudo naa pẹlu iṣẹ naa. Ẹyẹ adaba nla ni eyi.

Sugbọn, ah, arakunrin, Isaiah 53 sọ fun wa nipa Ẹni kan ti o wa lati ile pẹlu ohun gbogbo ti o dara:

A sa A ni ọgbẹ nitori irekọja wa, a pa A lara nitori aiṣedede wa, ina alaafia wa nibẹ lara Rẹ ati nipa ina Rẹ ni a ti mu wa larada.

50 Aisan, igbagbọ aṣan, ati awọn eṣu ti de wa mọlẹ. Ko si ọna abayọ, ijo lọ ni ọna ti o kuna, o ti gba ọna ijọ aladamọ lọ (awọn Farisi, Sadusi ati fifọ awọn ìkòkò ati awọn abọ́), Ọrọ Ọlọ́run ko si ni ìsapá mọ. Sugbọn Adaba kekere sọkalẹ, ohun kan ni o si lee sẹlẹ, Olurapada kan ni lati wà.

Nitori pe a pa A lara, a fọ Ọ, a lu U, a fa A ya sugbọn O mọ ọna Rẹ pada si ile. Nitori naa lati ibi agbelebu Calvary nibi ti a ti pa A lara, ti a ti tẹ Ẹ, ti a ti fa A ya, gẹgẹ bi awọn ikooko kan lori Rẹ, O fo lati Calvary O si gunlẹ ni awọn ẹnu ilẹkun ọrun, ti O n wi pe, “O ti pari! O ti pari! Wọn ti di ominira, a lee wo aisan san bayi! A lee gba ẹlẹṣẹ la! Awọn onde lee gba itusilẹ!”

Bi o ti lẹ jẹ wi pe a sa pa A lara, a si ṣa A lọgbe, ninu ogun nla naa nigba ti ohun gbogbo lodi si I… Akewi naa ke:

Laaarin apata ti n ya ati oju sanmọ ti o sọkunkun,

Olugbala mi tẹ ori Rẹ ba o si ku

Sugbọn asọ ikele ti a ṣi, la ọna

Fun ayọ ọrun ati ọjọ ailopin

51 Mo ti jẹ alara-ai-balẹ ni gbogbo aye mi. gẹgẹ bi ọdọmọde, ohun kan wa ti ko fi mi silẹ ri, ti o maa n ja mi laya, ni bi lọdun meje meje ni o maa n ṣẹlẹ simi. Arakunrin Jack ranti igba ti mo kọkọ bẹrẹ ti mo fi òde iwaasu silẹ fun bi odidi ọdun kan; nnkan kan sẹsẹ sẹlẹ ni.

Mo ranti ọjọ ti Juanifa Hemphill… Mo ro wi pe orukọ obinrin naa bayi ni Juanita Kelly, o fẹ Arakunrin Kelly lẹyin iku ọkọ rẹ. Anna Jeanne, mo ni fọto wọn ati awọn nnkan, wọn jẹ…oun…awọn ọmọbinrin mejeeji ati Arabinrin Moore, wọn ni ẹgbẹ mẹta kan ti n kọrin. Wọn kọ orin naa, n ko lee gbagbe: Wíwó kọja Iwọ Oorun, Arakunrin Jack, ṣe ẹ ranti, mo roo bẹẹ, ti a n bọ lati Florida. Awọn ọdọmọbinrin ti o dara ni wọn!

52 Mo si ranti owurọ naa nigba ti awọn ọdọmọde olorin ẹgbẹ afi-ede ajeji ṣe ẹri Ẹmi Mimọ kan wa lati ariwa orilẹ-ede yii ni Michigan nibikan, awọn ọmọbinrin naa duro nibẹ nigba ti Arakunrin Hooper, … mọ ri arakunrin naa nihin ni alẹ ijelo, o lee ma si ni ibi bayi, Arakunrin Ed Hooper. N jẹ ẹ wa nihin, Arakunrin Ed? Emi ko ro pe o … Wọn joko nihin ni alẹ ijelo. Ọpọlọpọ yin mọ ọ. Oun ati emi ati Arakunrin Hooley, a ti n kuro. Awọn ọmọbinrin naa duro nibẹ ni ibi igun kan wọn n kọrin naa, wọn fun wa, ikọọkan wa ni ododo omi oronbo ti wọn yọ, lati inu irun wọn (o jẹ ibi ti a ti wo were naa san nibẹ lọhun, ti awọn ohun nla ti ṣẹlẹ.)

Bi a ti n bọ loju ọna ti inu mi n dun bi o ti lee dun to, lojiji o wa si ọkan mi; ọdun kan lẹyin ki n to pada fun ikiri-waasu lẹẹkan sii. O tilẹ fẹ ẹ lee pa mi.

53 Lati igba ti mo ti wa ni ọdọmọkunrin, mo maa n sọ wi pe emi ko mọ ohun ti iran jẹ. Ọdọmọkunrin kekere, mo maa n sọ wi pe, “Bi mo ba lee wọ inu awọn iranran yẹn, ki n si ri i pe ara mi yoo ya.” Lakoko naa… mo maa n fẹ lọ si ile-iwosan Mayo lati wadi ohun ti o n ṣe mi. awọn dokita ni bẹ…

Inú maa n kan mí ati ah, ole! Arakunrin Jack ran mi lọwọ ni agbegbe ile. Mo maa n rin yi ayika ile ka, omi elepo gbigbona bẹẹ yoo ma jade ni ẹnu mi, n o si rin lọ si ibi aga iwaasu, n o si gbadura fun awọn ti aisan wọn buru ni ilọpo meji ju temi lọ, a o si wo wọn san. Mo ti ri ti wọn gbe ọwọ mi le ẹni ti o ni arun jẹjẹrẹ ni oju rẹ, ti jẹjẹrẹ si kuro ni oju rẹ, ti mo duro nibẹ ti aisan yoo maa ṣe mi tobẹẹ ti n ko lee dide duro.

54 Ẹyin ko mọ ohun ti oju mi ti ri -inira ti ọpọlọ. Ni ọdun meje meje ni o maa n wa ni gbogbo igbesi aye mi. Ipo ti mo wa bayi ni eleyi, ọdun meje lẹrẹ mẹjọ.

A ti ni mi lara to bẹẹ gẹ ti mo ni lati sọkun, mo bẹbẹ mo rọ Ọlọ́run.

Mo ranti nikẹyin nigba ti mo ro wi pe mo ni owo ti o to lati lo si ile-iwosan Mayo fun ayẹwo, wọn wi pe, “Awọn yoo wa lawari ohun ti o n fa a.” Iyawo mi ati emi, Bekky ti o wa lẹyin lọhun, Sarah si jẹ ọmọbinrin kekere nigba naa, mo ṣẹṣẹ bẹrẹ iṣẹ-iriju ipolongo iwosan nipa adura, a si gbera lọ si ile-iwosan Mayo.

Mo la ile iwosan yii kọja. Alẹ ọjọ ti o sa aaju ọjọ ti mo ṣe ayẹwo ti o kẹyin, mo ji lati oju orun, mo si joko lori ibusun ti mo n wo yika. Mo si wo iwaju mi, ọdọmọkunrin kekere kan wa, ti o jọ mi gẹlẹ, sugbọn o jẹ ọmọ ọdun bii meje, mo si wo o, emi si ni. O si duro lẹgbẹ kukute igi kan. Ati ni ori igi yii…

55 Eyi keyi ninu ẹyin ti n ṣe ọdẹ ọkẹrẹ mọ wi pe ẹ lee fi igi kan ha ara igi ti ọkẹrẹ wa ninu rẹ, yoo si dẹruba ọkẹrẹ naa, yoo si sa jade bi o ba wa ninu iho igi naa.

Mo si n ri nibẹ nibi ti ọkẹrẹ ti wa, mo si ro o wi pe, “iru ọkẹrẹ wo ni iyẹn? Mo si ha igi naa. Nigba ti mo ṣe bẹẹ, mo jẹ ẹni ọdun meji-din-ni-ogoji. Mo ti kuro ni ọmọde ti mo jẹ tẹlẹ. Mo tun ha ẹẹka igi naa ati lati inu iho igi ti o wa ni ilẹ naa ni ọkẹrẹ kekere kan ti ko gun pupọ ti jade, o dudu, o fẹrẹ dudu kirikiri tan, o dabi ẹni pe awọn omi kan n fo jade lara rẹ, o jọ eṣu ju ọkẹrẹ lọ.

56 O si n wo mi taara. Mo si la ẹnu mi lati wi pe, “O daa o… nigba ti mo si ṣe bee, oun … ki ẹni kan to lee sẹ oju, o fo simi lẹnu, o si wọ inu ikun mi lọ, o si bẹrẹ sii fa mi ya pẹrẹpẹrẹ. Mo si jade lati inu iran naa. Ọwọ mi mejeeji si wa loke, mo n wo, mo si bẹrẹ sii pariwo pe, ”Ah Ọlọ́run saanu fun mi! O n fẹ pa mi ni!“

Mo si gbọ ohun kan ninu iyara naa ti o wi pe, “Ranti pe, inchi mẹfa pere ni gigun rẹ.”

Melo ninu yin ni o ti gbọ itan naa? Mo ti sọ eyi fun yin ni ọpọ igba, awọn ara Ago naa.

O dara, o tẹsiwaju lati maa yọmilẹnu bakannaa.

Dokita ile-iwosan Mayo, ni ọjọ keji yẹ mi wo. O wi pe, “Baba rẹ jẹ ara Irishi, o si mu ọti. Iya rẹ jẹ aabọ ara India, eleyi jẹ ki o jẹ ẹni ti ki i ṣe ojulowo iru-ẹda. Nitori naa iwọ yoo jẹ… O jẹ ẹniti ara rẹ ko balẹ, to bẹẹ ti eleyi ko le fi ọ silẹ. Yatọ si eleyi, ko si ohun to nṣe ọ. Ṣugbọn eyi wa ninu ọkan ti ko si ẹniti o lee ṣe ohunkohun sii”. O wipe, Iwọ yoo…. O wi pe, “Nigba ti ẹnikan ba ku, wọn ko ni lee ṣe ayẹwo iku ti o paa, nitori pe ọkan rẹ ti lọ. O sọ wi pe, aisan yii yoo ṣe ọ ni titi o o fi ku.”

57 Ọkunrin naa dokita mi tẹlẹ sọ wi pe, “Baba mi ni aisan naa o si ku ni ẹni ọdun marun-din-ni aadọrun, abi ọmọ ọdun aaadọrun, ni bi i ọmọ ọdun yẹn.” O wi pe, “osu kan tabi meji ki o to ku, oun ṣe ayẹwo rẹ. O ni aisan yii ni gbogbo aye rẹ, yoo maa ni ni,” o ni, “Afiṣeni.”

“Awọn kan,” sọ wi pe awọn ni in, wọn maa n ni inu fufu.“ O wi pe ”iru eyi ti i pa eniyan ni yẹn.“ O wi pe, ”Orisi rẹ keji, pelu awọn obinrin ti wọn ko ri nnkan osu mọ, wọn yoo ma ke ni. O jẹ eyi ti i ma mu aarẹ ba ni,“ o wi pe, ”Awọn ẹni-igba-atijo ma nṣe pe e ẹni naa 'ni ohun ibanujẹ,' ko nì fi wọn silẹ,“ o ni, ”Bi iyẹn ba n ṣe eniyan, inu yoo maa kan o ni,“ yoo maa mu ọ kanra ni.”

Mo ni, “sugbọn alagba, emi ko…” Mo wi pe “inu mi maa n dun ni”

O wipe, “iyẹn daa, ti ẹ yatọ si ti gbogbo awọn eniyan ti nnkan yii maa n ṣe ni,” o ni “titi iwọ yoo fi ku ni aisan yii yoo ma ṣe ọ.” “Ah, ohun ti o lee mu irẹwẹsi ba ni ni eyi!

Sugbọn awọn ọrọ naa, lati roo wo, “Ranti, gigun rẹ ko ju inchi mẹfa lọ,” ọrọ yii ko fi mi silẹ, gẹgẹ bi iyawo mi ọwọn ti o joko sẹyin lohun ṣe lee jẹri si i. bi ọdun ṣe n gori ọdun, mo ti maa n ronu nipa eyi.

58 Ati bayi ti mo n lọ si oke okun ni igba ti o kẹyin yii, mo… ki n to lọ… o daa, mo pada si ile mo si lọ lati ṣọdẹ ọkẹrẹ. Mo ba jade kuro ninu ọkọ pẹlu Arakunrin Banks Wood, ẹni ti o n gbọ mi laṣalẹ yii, mo si bẹrẹ sii sare gun oke kan, o dabi ẹni pe ọkan mi yoo fo jade ninu mi.

Mo beere lọwo Dokita Sam Adair, “Mo ni, ”kinni o n fa eleyi?“

O wi pe, “Nigba-ku-gba ti eyi ba sẹlẹ si ọ, lọ lo ẹrọ ti n sayẹwo ipo ti ọkan wa.”

Mo ni, “o ti daa.”

O wa sẹlẹ ni ọdun ti o tẹlee, mo si lọ lo ẹro-asayẹwo ọkan, o wi pe, “ko si ohun ti o ṣe ọkan rẹ,” o wi pe ara-aibalẹ ni o nṣe ọ.“ Mo bẹrẹ si n bọ ni ile.

59 Dokita miiran ti o jẹ ọrẹ mi daadaa sọ fun mi pe, “ọkan rẹ ni nnkan ṣe, ọrẹ mi,” o wi pe, “Tete yaa sọra o.” Eyi jẹ ọdun ti mo pe Arakunrin Moore, ti o si pe ẹlomiran lati waasu ni ipo mi, nigba ti mo lọ sọdẹ agbo yẹn pẹlu Arakunrin Fred. Emi yoo gun ori oke bi mo ti sẹ nigba ti mo jẹ ọmọ ọdun mẹrin-din-logun, ti mo n gun ibusọ lẹyin ibusọ, ti mo n sare, ti ko si da mi laamu rara. Ṣe ẹ rii?

Mo pada wa mo sọ fun Sam. O wi pe, “O da a, nnkan kan wa ti o kuna, o ni tete yaa sọra.”

Lẹyin naa mo ri iran dokita atijọ kan duro pẹlu awọn… dokita ti igbaani pẹlu irinsẹ dokita ti a fi n yẹ mimi ọkan wo ni ori apa rẹ. O duro ni iwaju mi, lọjọ kan, o wi pe, “Ma jẹ ki wọn sọ fun ọ pe ọkan rẹ ni, o ti, inu rẹ ni.”

Mo wa roo, “O daa, n o sa gba ọrọ yii gbọ nitori pe iran kan ni.”

Wa wa o

60 Mo n mura lati lọ si Ilẹ Awọn alawọ dudu… lati gba awọn abẹrẹkan. Mo nilo lati gba awọn abẹrẹ kan ki n le lọ si Afrika. Ohun ti ofin sọ niyẹn. Nigba ti mo si n gba awọn abẹrẹ yii, o wi pe, “N ko ri ohun kan ti o kuna pẹlu rẹ,” o wi pe, “Ipa ẹjẹ Rẹ kan, iwọn ẹjẹ rẹ jẹ mẹrin-din-lọgọrun. O wi pe bi o ba jẹ ọmọ-ọdun mẹrin-di-logun, ẹjẹ rẹ ko lee da a ju eyi lọ.” O si wi pe, “ko-ko-ko ni gbogbo ẹya ara rẹ le. Ẹdọ foro rẹ bakan naa,” o ni “ara rẹ da saka. O ko ni itọ suga, ko si ohunkohun ti ko dara.”

Mo ni, “O sé ò.” Nitori naa mo ṣe iyẹwo ti ara, lati lee gba iwe-ẹri ti ilera ti n o fun igbimọ.

O wi pe, “Njẹ o mọ ohunkohun nipa ilera rẹ?”

Mo wi pe rara, “Ayaafi inu ti o maa n kan mi ni gbogbo igba.

O wi pe, “N o sọ fun ọ.” O wi pe…

Mo wi pe, “Wọn ti ṣe ayewo mi. Mo ti lọ si ile-iwosan awọn Mayo, ati ibi gbogbo.

61 O ni, “Ni suru diẹ o,” o wi pe,“ogbẹ inu nigba miiran maa n kere tọ bẹẹ ti ẹrọ ti o fi n yẹ ọgbẹ-inu ko ni rii, ati ni igba miiran o lee tobi pupọ ju fun ẹrọ naa lati ri, nitori Ẹrọ Aya Aworan inu ara (x-ray) jẹ ojiji lasan, o lee ma ri ọgbẹ inu kekere, ko ni farahan. Ọpọlọpọ ọgbẹ inu kekeke ko ni fojuhan.” O ni oun mọ dokita agba kan ti o ti ni irinsẹ kan ti wọn ni, wọn lee mu o sun pẹlu eroja sodium pentothal kekere kan, wọn a ti ẹrọ kan bọ ọ ni ọfun lati ibẹ wọn yoo si wo inu rẹ ki wọn si mọ ohun ti o kuna nibẹ.“ O ni iru awọn eniyan bii ti rẹ naa ni, Kristẹni ni.” O ni, “O ko ṣe lọ ri i.”

62 Mo gba orukọ ẹni naa: Dokita Van Ravensworth. Nitori naa, nigba ti mo de, mo lọ ri dokita agbalagba naa. Ah, ọkunrin ti o dara ni lati Dutch East Indies, lati inu ọpọlọpọ awọn akiri-waasu. O si ti gburo mi tẹlẹ o si ti ka iwe mi ri, ah ah, o saa bọ mi lọwọ, o wi pe, “Arakunrin Branham, inu mi yoo dun lati ṣe e fun ọ.” O wipe, 'N o sọ fun ọ ohun ti iwọ yoo ṣe. Bi o ba di ọṣẹ ti n bọ, maa bọ ni ile iwosan nihin,“ o sọ pe, ”pe mi ki o to wa o.“ O ni mo ni lati fun ọ ni abẹrẹ kan.” O sọ wi pe, “Nigba ti mo ba ṣe bẹẹ,” o ni “yoo jẹ ki o sun fun iṣẹju marun un.”

Ọmọ mi obinrin laipẹ gba abẹrẹ yii ki o lee yọ eyin rẹ kan kuro, ati ọmọbinrin Arakunrin Norman pẹlu ṣe bẹẹ. Mo wa ro o wi pe,“Orun iṣẹju marun un, ”pe eyi ko lee yọ mi lẹnu.“ ”Nitori naa, mo ri wi pe yoo dara fun mi bi mo ba wo o.

63 Ati ni owurọ ọjọ keji, mo dide lori ibusun mo wo yika, mo wo ibusun keji lẹgbẹ mi, iyawo mi nibẹ ko i tii ji. Lati oju ferese, mo wo awọn oke Catalina nla naa nibi ti mo n gbe, mo si wo oke nibẹ nibi ti Angẹli Oluwa ti fi Ida le mi lọwọ, nibi ti awọn Angẹli meje ni ti ẹ ri ninu awọn aworan naa ti fi ara han, ti awọn ohun nla nla ti sẹlẹ,

Mo si wo, bi mo si ti wo, mo duro lẹgbẹ igi naa, nibi ti ọkẹrẹ naa gbe wa. Mo wo ibẹ, mo wa sọ wi pe, “Ile ọkẹrẹ naa ni yẹn.” Mo wa ro wi pe, “A ko mọ boya o si wa nibẹ? (ninu iran naa). Mo fi nnkan ha ẹgbẹ igi naa, bẹẹ ni o jade. Ki n to sẹju mi (o jẹ ọkẹrẹ ti o ṣajeji julọ ti mo tii rii, bayi o ni lati mọ isẹ-iriju iwaasu mi, ki o to lee loye awọn ami ati awọn nnkan wọnyii), o bẹ lu mi, sugbọn o tase mi. O tase ẹnu mi, o wa kọlu mi laya o si bọ lulẹ.

Bi o ti sẹ bẹẹ, mo gbọ ti nnkan kan sọ pe, “Lọ si Oke Catalina.”

64 Mo wa yi po mo ni, “Meda, ololufẹ ṣe o ti ji?” Mo si jii. O ni kinni o n sẹlẹ? O jẹ bi aago marun owurọ.

Mo ni, “mo n wo ita nibẹ, mo si ri ọkẹrẹ naa lẹẹkan sii, ololufẹ.”

“O ni ọkẹrẹ wo?”

Mo ni, “Eleyi ti mo ri ni ile-iwosan Mayo.” Mo ni, “N jẹ o mọ ohun ti o sẹlẹ? Lakoko yii, o tase ẹnu mi. Ko bọ si mi lẹnu, o kọlu aya mi ni.” Mo ni, “Yin Ọlọ́run logo! Mo ti n foju sọna … lati igba ti mo ti wa ni ọdọmode ni mo ti n foju sọna lati ri ki eleyi ṣẹlẹ, (ani ki n to tilẹ mọ ohun ti iran jẹ), bi mo ba ri eyi ti o ṣẹlẹ, nigba naa mo wi pe, ara mi yoo da. Ohunkohun ti o ba sọ eyi fun mi, ohun ti yoo jẹ niyẹn. Ati fun ogoji ọdun mo ti fi oju sọna fun eleyi lati sẹlẹ, ati nibẹ ni o ṣẹlẹ.

Tẹlẹ, nigba ti mo wa ni ile-iwosan Mayo, ni akoko kan naa ti mo wa nibẹ nigba ti wọn fun mi ni iṣẹ naa, ti mo si ri iran naa…

65 Iya mi arugbo naa ti lọ sinu Ogo bayi, obinrin ajeji ni. Ala mẹta tabi mẹrin ni o la ni gbogbo aye rẹ, wọn si maa a n jẹ ootọ ni. O sọ fun mi pe, bi o ba si ti da ẹnu lee, n o wi pe, “Ẹ dakẹ… Mama, n o sọ fun yin iyoku ala ti ẹ la.” Ṣe ẹ rii?

Nitori nigba ti ẹ ba n sọ ala ti ẹ la fun mi lati tumọ, ẹ ki i ma n sọ ohun ti o ṣẹlẹ gẹlẹ. Sugbọn nigba ti mo ba tun ala yii ri, n o ri ala ti o la bi o ti laa gẹlẹ oun yoo si sọ fun mi ohun ti ala yii jẹ. Ṣe ẹ rii? O ko ni lati sọ fun mi ala rẹ, Ọlọ́run funra ara Rẹ ni yoo sọ ọ fun mi. Ṣe ẹ rii? N o wa rii. N o wipe, “O ko sọ eleyi ati eleyi ninu ala naa fun mi.” Ṣe ẹ rii? Nitori naa Ọlọ́run ti O lee tumọ ala, O le fi ala naa funrarẹ han ni. O lee fi ala han, ki o si tumọ rẹ. Ati nigba naa…

66 O dara, ṣe ko si iru nnkan bẹẹ ninu Bibeli, o wi pe, “Bi o ba lee… mo sẹsẹ ranti rẹ bayi ni. Ṣe Danieli rii? Rara o, Josefu. Josefu. O daa O wa nibi kan ninu Bibeli. Mo sẹsẹ ranti rẹ ni. O wi pe, ”Bi o ba lee fi han mi … Bi o ba lee sọ fun mi ohun ti …“ Ah, Oba Nebukadinesari ni, bẹẹ ni. O ni, ”Bi o ba lee… Bi o ko ba lee…“

Awọn pedan-pedan naa sọ wi pe, “Sọ ala rẹ fun wa.”

O wi pe, “mo ti gbagbe rẹ” Bẹẹ ni mo ranti rẹ, mo sẹsẹ ro o nigba naa ni.

Wa kiyesi bayi. Ati Mama wi pe “Billy,” nigba ti mo pada de, iya wi pe “Ọmọ mi wa, joko,” o wi pe, “Mo la ala ti o sajeji, mo la ala pe mo ri ọ ti o n saisan, ti o si ti fẹrẹ ku, pẹlu aisan inu rẹ naa bi o ti maa n sẹlẹ si ọ.” Aimoye ounjẹ ni o ti ṣe fun mi! O si wi pe, “O n kọ ile kan lori oke kan.” O si wi pe, “Mo ri ẹyẹ adaba funfun mẹfa fo sokalẹ lati ọrun wa, wọn ṣe ku-ku-ku, ni ọna lẹta 'S', wọn si joko le o laya. O si n wo, eleyi ti o wa ni iwaju si n gbiyanju lati sọ ohun kan fun ọ.' O ni, ”Awọn ẹyẹ adaba funfun ti ara wọn n dan monamona ni. Wọn si gbe ori wọn le ọ laya wọn si n ṣe kuu kuu kuu. O ni, “ko ye mi, o ni ”Wọn saa n lọ wọn si n ṣe 'kuu kuu kuu,“

Mo ni, “Aa, mo rii, yin Oluwa!” O sọ pe, wọn tun kọ lẹta 'S' lẹẹkan sii, wọn si pada lọ si oju ọrun, wọn n

ṣe kuu, kuu, kuu, wọn si n pada lọ si ile.“

O daa, ẹranko kekere ti mo ri, inchi mẹfa ni gigun rẹ. Awọn ẹgbẹ adaba ti Mama ri jẹ mẹfa. Onka mẹfa ko pe. Mo mọ wi pe lọjọ kan, emi yoo ri ikeje. Eyi ni ọkunrin ti n jiya. Bẹẹ bẹẹ ni o n lọ.

67 Laarọ ọjọ naa mo dide lẹyin ti mo ti ri ìran naa, mo ṣe igboran si Oluwa. Mo mu ọmọkunrin mi kekere, Josefu lọ si ile-iwe (O n tẹti simi bayi ni Tucson). Mo mu lọ si ile-iwe mo si sọ fun Meda pe emi ko mọ igba ti n o pada.

Bẹẹ ni mo gbera lọ si Oke Catalina, mo lọ si ẹsẹ awọn oke naa, bẹẹ ni mo si lọ si ibi ti Angẹli Oluwa ti fi Ida le mi lọwọ. Ni kutukutu owurọ mo bẹrẹ si i gun ori oke naa lọ.

Dipo ki n gun awọn tente oke naa lọna yi lọ (ti o jẹ wi pe oke naa kun fun awọn ejo, akeeke, ẹ mọ bi Arizona ṣe ri), mo yipada si ọwọ ọtun mi. O hun kan so wi pe, “yipada si ọwọ ọtun rẹ.” Mo si lọ si tente ori oke naa. Mo si lọ yika, mo si n lọ yika awọn apata naa ti o jẹ wi pe o sọwọn ti ẹni kẹni to lee de awọn ori apata naa.

68 Ni bii aago mọkanla owurọ, mo n lọ si ibi palapala okuta kan, nibẹ nibi ti awọn… ibi kekere kan ti o ya wọnu si ibi opo agbọnrin kan. Mo ti bọ ẹwu ọkunrin mi kuro lọrun mi, ate mi n bẹ lọwọ mi, nitori wi pe mo n laagun yọbọ ni. Nitori naa, mọ ya wole nibẹ, bi mo si ti ya si ibi palapala okuta naa, mo ni imọlara Iwalaaye Oluwa, mo si ate mi kuro mo si wo yika. Mo ro pe, “O wa nibi kan nihin. Mo mọ pe O wa nihin.” Mo ro wi pe, “kinni? Mo gbe igbeṣẹ diẹ sii. Mo ni, ”Oluwa, O wa nihin nibikan.“

Mo si wo, nibẹ ni ọkẹrẹ kekere naa wa, o ti bẹ lu nnkan, o si tase rẹ, o wa kọlu igi ẹlẹgun kan (awọn ẹgun ti o maa n fo mọni). O wọ inu ori, aya ati ikun rẹ, o si ti ku. Ọkẹrẹ kekere ti o sajeji pupọ naa, o ti tase ẹnu mi, o wa kọlu igi ẹlẹgun. Ohun Oluwa si sọ wi pe, “Ọta rẹ ti ku. Mo duro nibẹ, mo si n gbọn. Mo gbe ẹsẹ mi mo si…

69 Lọpọ igba awọn ẹyẹ igun yoo ti jẹẹ. Mo pa ejo kan ni ọjọ diẹ lẹyin eleyi nibẹ, o si wa ni ile ni oju titi fun bi i ọgbọn iseju. Awọn ẹyẹ idi ati ẹyẹ igun maa n fo kọja nibẹ, wọn yoo si gbe e ni kia nibẹ. Mo pa ejo buburu kan (o jẹ ejo ti o lewu julọ ti a ni) ti o wa lẹgbẹ mi nibẹ lẹyin awọn ọjọ diẹ lẹyin naa. Mo si bẹrẹ sii i pada lati gbe ki n fi han awọn eniyan, awọn igun ti gbee lọ, awọn ẹyẹ dudu nla kan ma n kọja nibẹ.

Ọkẹrẹ naa si ti wa nilẹ nibẹ lati igba ti mo ti ri iran naa, bii ọjọ meji ki n to de ibẹ. Mo gbagbọ pe ọjọ Satide ni, mo si lọ sibẹ ni ọjọ Aje (Monde). Nibẹ ni o wa ti o ti ku silẹ nibẹ. Mo fi ẹsẹ mi tẹ ẹ.

70 Mo lọ pada yika, mo joko pada, mo joko nibẹ, mo si sọkun diẹ, mo gbadura, ti mo n wo Tucson, ni isalẹ ni ọpọlọpọ ibusọ ni isalẹ ibi ti mo ma.

Mo tun yii mo tun pada wa, ọkẹrẹ naa si wa nibẹ. Nigba ti mo wọ inu palapala okuta naa, Ẹmi Ọlọ́run sọkalẹ wa sori mi lẹẹkan sii.

Mo lọ yika, mo sọkalẹ oke naa. Mo lọ sọ fun iyawo mi, mo ni, “Ololufẹ n ko mọ bi yoo ti sẹlẹ, sugbọn emi yoo bọri aisan yii.”

Dokita Ravensworth, nigba ti o ṣe ayẹwo mi, o sọ wi pe, “ko si bi o ṣe lee bọri aisan yii.” O fun mi ni abẹrẹ pentothal, ti o yẹ ki o kun mi ni orun fun iseju marunun, mo si sun fun wakati mẹwa. Nitori ohun naa… asìpirìní lasan maa n mu mi sun. o wa fun mi ni abẹrẹ, o na ẹrọ kan simi lọfun. Nigba ti mo ji, o sọ fun mi laaarọ ọjọ keji, o wi pe, “Ẹniọwọ, o ṣe mi laaanu lati ṣọ fun ọ, sugbọn, ”awọn ẹgbẹẹgbẹ inu rẹ le pupọ, ti o fi jẹ wi pe wọn ti gan.“ O ni oun ko ti i ri iru rẹ… o lo ọrọ 'gasitiriti'. Nigba ti mo lọ wo o ninu Iwe ti n tumọ ọrọ, o wi pe, ”ohun ti o ti gan patapata.“ O wa wi pe ”o ko lee bori arun yii.“ O wi pe ”Ni gbogbo igba ni iwọ yoo maa ni.“ Nkan yii nì i ba ti mu mi rẹwẹsi kanni ki i ṣe ti iran Oluwa yii.

71 Ni ọjọ keji Oun kan sọ wi pe, “Pada lọ si ori oke naa.”

Ati ni ọjọ naa kaka ki n gba ọna kan, A dari mi lati gba ọna miiran. Mo si n duro nibẹ, ti mo si n wo, mo ri ti o duro ni iwaju mi nibẹ ni ẹyẹ adaba funfun keje naa duro ti o n wo mi. Mo nu oju mi. Mo wipe, “Dajudaju ìran ni, dajudaju iran ni.” Mo wo, mo si wi pe,“ Adaba kekere, nibo ni o ti wa?” O jẹ adaba ti o rẹwa ti o si funfun, ko lee jẹ ẹyẹle, ohunkohun ti o lee jẹ, ni ọna jinjin rere ninu aginju.

Ọlọ́run Olodumare ti o ji Jesu Kristi dide kuro ninu oku, iranṣẹ Ẹni ti mo jẹ, ati Ọrọ Rẹ ti O wa ni ṣiṣi niwaju mi, mo mọ wi pe otitọ ni mo n sọ, n ko parọ.

Nibẹ ni adaba naa ba si, ti o ba sibẹ ti o n wo mi. Mo rin yika, mo ro o, “Dajudaju iran ni.” Mo yi ori mi pada. Mo wo ẹyin, nibẹ, ni o bà si, awọn iyẹ funfun balau, ti o dabi ojo didi bi o ṣe lee ri, ẹsẹ rẹ olomi orombo ati iko olomi-orombo ti o ba sibẹ ti o n wo mi. O si n wo iwọ-oorun taara. Mo rin yika rẹ bẹẹ. Nko ni fi ọwọ kan

an fun ohunkohun. Mo rin lọ soke loju opo naa, mo wo ẹyin o si wa nibẹ sibẹ ti o ba, ti o si n wo mi.

Arakunrin, gẹgẹ bi ọmọ Abraham. Emi ko ka ohun ti dokita so fun mi kun. Ara mi yoo da, lọnakọna.

72 Ni ọjọ kẹta mo pada si ori oke naa, mo n gun oke naa lọ soke tente. Ọpọlọpọ yin mọ iran nipa Oloye Ara India naa ti o n gun ogiri kekere naa lọ si Iwọ Oorun. Oun kan pe akiyesi mi kuro lọ si ibi apata nla kan nibi i aago mejila ọsan, o wi pe, "Gbe ọwọ rẹ lori iyẹn ki o gbadura." Ọlọ́run ọrun mọ wi pe otitọ ni eyi.

Mo gbe ọwọ mi le apata naa mo si gbe oju si oke ọrun mo si bẹrẹ sii gbadura, mo si gbọ ohun kan ti o n jade lati ori oke awọn apata naa nibẹ, o wi pe, kinni o gbe aya rẹ le naa?" Mo si dide bii eyi, gbogbo ejika mi ni a ko fi aṣọ bo…ti ko si aso lati ibi ibadi mi soke, nitori ti ooru mu. Mo wo ẹyin. Nibẹ ni a kọ ninu quartz, ninu apata, "Ẹyẹ Idi funfun". Ohun ti iran naa sọ gẹlẹ pe iṣẹ ti yoo kan yoo jade nipa rẹ.

Ara mi mi bẹrẹ si i gbọn, mo salọ si ile mo mu ẹrọ ayaworan mi mo si pada wa ni ọjọ keji, mo si ya aworan naa. O si wa nibẹ, a kọ ọ sori apata, "Eyẹ Idi funfun." Adaba ti o n dari Ẹyẹ Idi.

73 Lọnakọna mo mọ. N o sọ fun yin ki o to sẹlẹ. Dokita naa jẹ dokita ti o dara, ko si iyemeji, mo ro wi pe o jẹ ọkunrin daradara, sugbọn mo mọ pe emi yoo bori aisan naa. O ti pari, o ti tan, ara mi yoo da.

Mo si n ro o gẹgẹ bi Ernie ṣe kọ orin naa ni iseju diẹ sẹyin lori Iye Adaba. Bawo ni kikọ orin na ṣee lọ? Ba mi bẹrẹ rẹ Ernie.

..… adaba funfun bi ojo didi (kọ orin naa pẹlu mi).

Ọlọ́run ran ifẹ Rẹ ti o mọ ti o si dun

Ami lati oke wa

Lori iye adaba

Mo mọ wi pe ẹsẹ meji ni Ernie kọ. N o fi ẹsẹ kẹta kun.

Noah ti n lọ soke sodo

Lori ẹkun omi fun ọpọlọpọ ọjọ

O wa ilẹ

Lorisirisi ọna

O ni wahala diẹ

Sugbọn ko wa lati oke.

Nitori Ọlọ́run fun ni ami Rẹ

Lori iỳẹ-apa adaba.

Lori iyẹ-apa adaba funfun

Ọlọ́run ran ifẹ Rẹ ti o mo ti o si dun

Anu lo jẹ lati oke

Lori iyẹ-apa adaba

Jesu, Olugbala wa

Wa si aye lọjọ kan

A bi I ni ibujẹ ẹran

Ninu ibujẹ ounjẹ ẹran

Bi A ti lẹ kọ ni aye

A ko kọ Ọ ni oke

Nitori Ọlọ́run fun wa ni ami Rẹ

Lori iyẹ-apa adaba kan.

Lori Iyẹ-apa Adaba funfun

Ọlọrun ran Ifẹ Rẹ ti o mọ, ti

o si dun

Ah, ami lati oke wa

Lori iyẹ-apa adaba funfun

Bi o tilẹ jẹ wi pe mo jiya

Ni ọpọlọpọ ọna

Mo sunkun fun iwosan

Lọsan ati loru

Sugbọn a ko gbagbe igbagbọ

Lati ọdọ Baba wa Ọrun

O fun mi ni ami kan

Lori iyẹ-apa adaba kan.

Lori iyẹ-apa adaba funfun kan

Ọlọ́run ran ifẹ Rẹ ti o mọ ti o

Si dun

Ah, Ami kan lati oke

Lori iyẹ-apa adaba kan.

Lori iyẹ-apa adaba funfun kan

Ọlọ́run ran ifẹ Rẹ ti o mọ ti o

Si dun

Ami lati oke wa

Lori iyẹ-apa adaba kan.

74 Ọlọ́run ọwọn, mo dupẹ lọwọ Rẹ fun awọn nnkan wọnyi. Baba. O fun Noah ni ami naa. O fun araye ni ami naa, O si fun mi ni ami kan. Ati ni ọjọ keji, riri ti mo ri ẹyẹ idi ti n fo naa, Ah! Ọlọ́run, iṣẹ kan n bọ wa bayi. Mo si gbadura, Ọlọ́run, pe ki O jẹ ki ki Adaba Ki o dari. Ẹ gba bẹẹ fun wa, Oluwa. O ti dari mi si igbagbo ti n ko ni tẹlẹ. Mo mọ Ọlọ́run, mo mọ pe gbogbo rẹ yoo dara, nitori naa mo dupẹ lọwọ Rẹ fun un, Baba.

Ati ni aṣalẹ yii, ran isẹ Rẹ sọkalẹ lẹẹkan sii Oluwa lori iyẹ-apa Adaba ti Ọrọ Ọlọ́run. Ẹ gba bẹẹ fun wa Baba ọrun ọwọn. Ati ki olukuluku ti yoo gba ibi pẹpẹ yii kọja ni aṣalẹ yii, ati ni ibi gbogbo ti ipade wa ni ayika orilẹ-ede, njẹ ki Adaba nla Rẹ ti igbagbo wọ inu ọkan wọn ki o si fun wọn ni igbagbọ, Oluwa, fun imularada wọn. Ranti pe Ọlọ́run ki i ṣẹ ojuṣaaju ẹnikẹni. O lee ran iṣẹ naa si Noah, O lee ran si Johannu Onitẹbọmi, O lee ran si mi, O si lee ran si awọn elomiran.

Mo gbadura pe ki Adaba naa ki o fo wa si ọkan kọọkan lọwọlọwọ bayii, Oluwa pẹlu iko wura kekere rẹ ki o si sọrọ kẹlẹkẹlẹ pe, “Nipa ina an Rẹ… Nipa ọgbẹ Mi ati nipa ina Mi a mu u yin larada.” Ọlọ́run jẹ ki a pa irekọja wa rẹ, ki a dari awọn ẹṣẹ wa ji wa, ki a si wo awọn arun wa san. O wa lọwọ Rẹ bayi, Baba. Ni Orukọ Jesu Kristi. Amin.

Pẹlu ori yin ni titẹba ni isẹju kan sii.

75 Awọn melo nihin ni yoo fẹ sọ wi pe, bi o ba lee ṣee, ti o si fẹẹ sọ wi pe, “Arakunrin Branham, mo ti kuna ni gbogbo ọjọ aye mi. Mo ti fẹ sin Oluwa, sugbọn ni aṣalẹ yii, mo ṣetan lati tuba. Gbadura pe ki Adaba naa fo wa sinu ọkan mi laṣalẹ yii. Mo lee ri ti o nlu iyẹ rẹ bi o ti n tọ mi wa.” Gbe ọwọ Rẹ soke, ṣe o o ṣe bẹẹ? Niwaju ijọ ti a lee fi oju ri yii, ha, ni gbogbo gbongan yii.

Lode ninu gbogbo awọn ikorajọpọ ti wọn wa yika orilẹ-ede, lọhun lọdọ Arakunrin Hunt ati Arakunrin

Coleman, lọhun naa pẹlu Arakunrin Leo ati awọn iyoku wọn, titi de Tucson, ati lọhun ni Branham Tabernacle, ni gbogbo bebe Iwọ Oorun, e gbe ọwọ yin soke nibi gbogbo pe, “Mo fẹ ki Adaba naa fo wa sinu ọkan mi ni aṣalẹ yii. Mu wa fun mi ifẹ didun Ọlọ́run lori iyẹ-apa Adaba funfun bi ojo didi, Ẹmi Mimọ. Mu u wa fun mi l'alẹ yii, Oluwa, ki o si mu igbagbọ ti mo nilo wa si ọkan mi.”

Ni Orukọ Jesu Kristi, mo gbadura, Ọlọ́run. Dari awọn ẹsẹ wa ji. Adaba ti a pa lara ni ti mu iṣẹ pada wa, ah Iwọ Ọlọrun, “O ti pari.” A gba eyi gbọ. Sa a fun wa ni igbagbọ lati gbaa gbọ, agbadura ni Orukọ Jesu. Amin.

Lori iyẹ-apa adaba funfun bii ojo dìdí

Ọlọ́run ran ifẹ ti o mo ti o si dun

Ami ni o jẹ lati oke wa,

Lori iyẹ-apa adaba kan.

76 Nibo ni adaba naa yoo ti wa? Emi ko mọ. Ko lee wa nibẹ ninu aginju naa bẹẹ. O ti o, o ti o, o ti o, ko le wa nibẹ. Ẹ ẹ ṣe ti o fi funfun? Baba ọrun mọ wi pe o funfun bi ẹ̀wù ọkunrin funfun ti mo wọ ni. Nibẹ ni o bà si.

Sugbọn o wa lori iyẹ-apa adaba funfun bii ojo didi,

Ọlọ́run ran ifẹ Rẹ ti o mọ ti o si jẹ aladun,

Ah, ami kan ni lati ọrun

Lori iyẹ-apa adaba kan.

Ọlọrun ran ifẹ Rẹ ti o mọ ti o si jẹ aladun,

Ah! ami lati oke wa

Lori iyẹ-apa adaba kan.

Ah! njẹ o ko ri ara rẹ bi ẹniti o rẹlẹ? Ẹ jẹ ki a bọ ara wa lọwọ, ki a si kọ orin naa.

Lori iyẹ-apa adaba funfun bi ojo dìdì

Ọlọ́run ran ifẹ Rẹ ti o jẹ alailabawọn

ti o ai jẹ aladun

Ami lati oke wa

Lori iyẹ adaba kan.

Ẹ jẹ ki a gbe ọwọ wa soke, ki a kọ orin naa:

Lori iye-apa adaba funfun bi ojo didi

Ọlọ́run ran ifẹ Rẹ ti ko labawọn ti o jẹ aladun

Ami lati ọrun wa

Lori iyẹ-apa adaba kan.

Noah ti sakolọ

Lori ẹkun omi fun ọpọlọpọ ọjọ

O wa ilẹ

Ni orisirisi ọna

O ni wahala diẹ

Sugbọn ko ti oke wa

Ọlọ́run ran ami Rẹ

Lori iyẹ-apa adaba funfun kan.

Lori iyẹ-apa adaba ti o funfun bii ojo didi

Ọlọ́run ran ifẹ Rẹ ti o jẹ alailabawọn,

Ti o si jẹ aladun sọkalẹ

Ami lati oke ọrun wa

Lori iyẹ-apa adaba kan.

Jesu, Olugbala wa

Wa si aye lọjọ kan

A bi I ni ibujẹ ẹran

Ni ibujẹ koriko ẹran

Bi o tilẹ jẹ wipe a kọ Ọ ni aye

A ko Kọ Ọ ni oke ọrun

Ọlọ́run fun wa ni ami Rẹ

Lori iyẹ-apa adaba funfun kan.

Lori iye-apa adaba funfun bi ojo didi

Ọlọ́run ran ifẹ ailabawọn ati aladun Rẹ

Ami lati oke ọrun wa

Lori iyẹ-apa adaba kan.

77 Ẹeṣe, emi ọkunrin arugbo kan, mo ti jiya ni gbogbo ọjọ aye mi, ẹẹṣe ti O wa wo mi san bayi? Mo gbagbọ pe n o gun ẹsin gba ọ̀na yii kọja lẹẹkan sii, mo ni iṣẹ kan lati mu wa. Mo si sọ fun Baba mi lalẹ yii, bi ọmọ kekere na ti ri ninu ala ni alẹ ijelo lori iyẹ-apa Adaba yii ninu oju ferese yii nihin, Oluwa, iransẹ Rẹ n jiyin fun isin. Amin. Mo ṣetan!

Lori iyẹ-apa adaba funfun bii ojo didi

Ọlọ́run ran ifẹ alailabawọn ati aladun Rẹ

Ami lati oke ọrun wa

Lori iyẹ-apa adaba kan.

Ẹ jẹ ki a gbagbọ bayi pe O ti n wa sori awọn ara ijọ bayi.

Lori iyẹ-apa adaba funfun kan…

(A n duro Oluwa)

Ọlọ́run ran ifẹ ailabawọn ati aladun Rẹ

Ami lati oke ọrun wa

Lori iyẹ-apa adaba kan.

78 Ẹyin ti ẹ ni kaadi adura, ni aarin ijọ yii, ẹ bọ si ita nihin, ẹ bọ si ita si ibi yii, ẹ dide duro, ẹ bọ siwaju aarin ijọ yii, ni abala ibi yii.

Lori iyẹ-apa adaba funfun bii ojo didi

Ọlọ́run ran ifẹ ailabawọn ati aladun Rẹ

Ami lati oke ọrun wa

Lori iyẹ-apa adaba kan

Lori iyẹ-apa adaba funfun bii ojo didi

Ọlọ́run ran ifẹ ailabawọn ati aladun Rẹ

Ami lati oke ọrun wa

Lori iyẹ-apa adaba kan

Lori iyẹ-apa adaba funfun bii ojo didi

Ọlọ́run ran ifẹ alailabawọn ati aladun Rẹ

Ami kan lati ọrun wa

Lori iyẹ-apa adaba kan.

Maṣe…

Ah! Lori iyẹ-apa adaba funfun bii ojo didi kan

Ọlọ́run ran ifẹ alailabawọn ati aladun Rẹ

Ami kan lati ọrun wa

Lori iyẹ-apa adaba kan.

79 Nibo ni adaba naa ti jade wa ni aginju? N o sọ wi pe: Ọlọ́run mọ pe Abranham nilo agbo kan fun ami kan, Jehovah Olupese ni. “Oluwa lee pese ẹbọ fun Ara rẹ.” Lati ronu lori rẹ! Ọlọrun kan naa, nipa imisi kan naa, nipa iru awọn-eniyan kan naa, ran adaba kan wa. Ọlọrun si ni. Jehovah lee pese ohunkohun ti O nilo.

Kilode, nigba ti o n bọ fun ipe adura yii, sọ fun Ọlọrun ki o pese fun o lori iyẹ-apa ẹyẹ adaba? Adaba naa, Ẹmi ti Ẹmi Mimọ, ki o fun ọ ni igbagbọ ninu ọkan rẹ lati gbagbo pe a o mu ọ lara da.

80 Mo n gbiyanju lati jẹ ki gbogbo wọn wa lori ẹṣẹ wọn, ṣe o rii. Mo n sọ bayi wi pe, arakunrin Brown wa ni ipo rẹ. Arakunrin Jack… Kinni o wi? (Ẹnikan ba Arakunrin Branham sọrọ.) O ti daa, o daa. Abala nihin, ẹ kọkọ gba ọna yii wa, a ti to ibẹ yẹn. Awọn abala ti o wa lọwọ ẹyin nihin ẹ to si ẹyìn awọn wọnyii ti ẹ o maa bọ tara nihin fun adura.

Wayi, o da mi loju, eleyi ko ni jẹ ila adura ti yoo ya, a o pe awọn diẹ, ni ki a lee gba adura fun ẹni kọọkan, bi a ba ṣe lee ṣe to.

Wayi, o din iwaasu mi ku diẹ (gbogbo yin ni ẹ si ri eyi, ṣe ẹ rii) kin n lee pe fun ila adura yii. Eleyi jẹ ila adura manigbagbe ni ibuọla fun awọn ọjọ nigba ti Arakunrin Moore, Arakunrin Young Brown, awọn aya yin gba yin laaye lati lọ, ti ẹ si wa ti a si jade lọ si California, ati ni gbogbo Arizona papọ, la gbogbo aṣalẹ kọja lati gba adura fun awọn alaisan.

81 Njẹ ẹ mọ nnkan? Awọn eniyan kan wa ti wọn n gbe loni ti wọn n ku lọ nigba naa, ti wọn si wa laaye bayi nitori akitiyan naa. Kin ni o ṣe? O gbe iwọsan nipa adura dide ni gbogbo ijọ ti o wa ni orilẹ-ede yii, nisisiyi bayi awọn ijọ alagba paapaa ati bẹẹ bẹẹ lọ. O pa ẹnu wọn mọ nitori o gba Ọlọ́run lati ta ami ororo le ẹni kan lati pa Goliath lati fihan pe o ṣee ṣe. Nigba naa ni iyoku wọn ni igboya (bẹẹ ni) wọn si jade lọ. A lee ṣe nitori pe O si ran ifẹ Rẹ lori iye-apa adaba kan.

Ẹyin Kristẹni, mo fẹ ki ẹ tẹtisilẹ. Bi n o ba duro nihin ki n gbiyanju lati tun sọ fun yin nipa isẹ agbara ti o ju ti ẹda lọ ti mo ti ri ti o ti ṣẹlẹ, ni awọn ọdun mẹta ti o ti kọja paapaa, n o si wa nihin titi di alẹ ọjọ Satide ti nbọ ti n o maa sọ. Emi ko tilẹ n sọrọ pupọ nipa rẹ, nitori o n dabi ẹni pe ko le ri bẹẹ. Sugbọn otitọ ni mo n sọ fun yin. Otitọ ponbele ni. A n gbe labẹ idari ti Jehovah nla alagbara, Ẹnikan naa ti O ti wa pẹlu awọn wolii ninu Majẹmu Laelae, ati pẹlu ijọ ninu Majẹmu Titun. O si wa nihin loni ti o n mu iyawo jade lati inu awọn Ẹya Alaikọla nitori orukọ Rẹ. Ẹ gba a gbọ. Ṣe e ko nii ṣe bẹẹ, ẹyin eniyan. Bi o ba gba A gbọ nigba ki-igba, gba A gbọ lọwọ lọwọ bayi. Eyi ni… mo fẹ ki o ṣe bẹẹ. A ko mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ laṣalẹ yii. A ko mọ ohun ti yoo ṣẹlẹ. A saa n duro labẹ ifojusọna ni.

82 Ẹ jọwọ, ni orukọ Oluwa Jesu mo bẹ yin gẹgẹ bi iransẹ Rẹ. Mo mọ pe nigba ti a ba ba ijọ eniyan lo, ohun gbogbo yoo dojuru ni nibẹ. Sugbọn, bi ẹ ba gba mi gbọ gẹgẹ bi iransẹ Oluwa, bi iyemeji kekere kan ba wa tabi … ẹṣẹ tabi, iyemeji, aigbagbọ“, Bi kin un rẹ ba wa ninu ọkan yin, ẹ ni ki Baba ki o mu u kuro ni kia bayi. ”Oluwa…“ Ati lẹyin naa nigba ti ẹ ba wa pẹlu igbagbọ ojulowo… Wayi ọwọ mi ko ni jamọ nnkan ayafi bi igbagbọ ba wa lakọkọ. Nigba naa ti o ba wa, yoo tan imọlẹ naa ni, a o si mu yin larada. Bẹẹ ni o ri ẹ mo wi pe ẹ o gba imularada. Ẹ o gba a gbọ.

83 Wayi i, n o gbadura fun ikọọkan yin. Nigba ti ẹ ba si ṣe eyi ẹ gbe ọwọ yin le ara yin, ki o si maa gbadura

fun ẹniti o gbe ọwọ le, lẹyin naa, n o wa mu yin lọ sọri ìlà fun adura. Gbe ọwọ rẹ le ẹnikan ti o wa pẹlu rẹ lori ila.

84 Ọlọ́run ọwọṇ, n ko mọ ọna miiran lati sọ awọn nnkan wọnyii, Oluwa. Mo saa mọ lati sọ ohun ti mo mọ pe o jẹ otitọ, Iwọ si ni ẹlẹri mi ni aṣalẹ yii pe mo n sọ otitọ. Igbagbọ mi, Oluwa, ati iwosan mi ni ọjọ iwaju, n ko mọ igba naa, n ko mọ bi yoo ṣe ṣẹlẹ, ko ye mi, sugbọn mo gbagbọ, Oluwa, pe mo gba ami lati oke wa. Adaba keje naa n bẹ nibẹ ihin ni gbẹyin gbẹyin, ati inchi keje ko ni pẹ pari lori ẹranko naa. O ti dopin.

Ọlọ́run, mo fẹ sin awọn eniyan Rẹ. Nitori naa mo gbadura, Ọlọ́run pe ki O ta ami ororo le wa to bẹẹ ni aṣalẹ yii pe ẹnikẹni ti a ba gbe ọwọ le, lee gba iwosan kii ṣe nitori pe o jẹ awa, sugbọn nitori o jẹ titẹle aṣẹ Rẹ. O wi pe, “Ami wọnyi i yoo tẹ le awọn ti wọn gbagbọ.” Oluwa, ran mi lọwọ lati gbagbọ, si ran ọkàn wọn lọwọ lati jẹ ilẹ igbagbọ. Ati lalapọ fun ogo Ọlọ́run, jẹ ki gbogbo alaisan ati alarun ninu ile yii (tabi ninu gbogbo ile ni gbogbo ayika orilẹ-ede) ti wọn n ṣe igbọran si awọn aṣẹ yii bayi, gba imularada. Ni Oruko Jesu Kristi, mo beere re. Amin.

85 Gbogbo yin ẹ ni igbagbọ, ẹ gbadura pẹlu wa. Wayi i, eyi ki i ṣe ila fun imọ-ọkan-yatọ.

(Ohun ko jade lori ẹrọ) Irẹwẹsi-ọkan, ẹru mo mọ ohun ti eyi… ẹni-ẹlẹni kekere kan, ọmọbinrin naa wi pe oun ko ti ni ibalẹ-ọkan ri laye oun. Ohun kan naa ti (awọn ọrọ naa ko ye ni) ko le sun, ara rẹ ko balẹ, iporuru ọkan.

Ọlọ́run ọwọn, ba mi jẹri, Oluwa, pe mo ti sọ otitọ. Bi àánú obinrin kekere sii ti n ṣe mi! Mo gbadura, Ọlọ́run, ki O ran an si i , ni irọlẹ yii, okun igbagbọ lati oke wa, ti o mọ wipe o di dandan ki O mu Ọrọ Rẹ ṣẹ, Iwọ yoo si pa gbogbo Ọrọ Rẹ mọ. Jẹ ki Ọlọ́run ọrun mu ẹru yii kuro l'ọkan arabinrin mi. mo si ṣe igbọran si Ọ nipa gbigbe ọwọ lee, ti mo si da ẹru naa lẹbi. Ni oruko Jesu Kristi, n jẹ ki o jade kuro ninu rẹ. Amin.

Wayi, mo mọ, arabinrin. O gba mi gbọ bayii. Bi o ba lee bẹrẹ lati ibi yii lọ nibi ẹgbẹ agbelebu, lati alẹ yii ki o kọ̀ pe o aisan yii, ṣe o rii. “Maa tẹ siwaju ki o maa sọ wi pe, ”Emi ko ni i mọ,“ yoo si fi ọ silẹ.

86 Arabinrin Palmer. Arabinrin wa, ọkọ Arabinrin Palmer jẹ ọrẹ mi ọwọn, ojiṣẹ Ọlọ́run lati Georgia tabi Alabama, Georgia. Georgia. O si n wa si Agọ. Nigba ti mo ba n waasu, ninu Agọ, wọn maa n wakọ wa fun ẹẹ́dẹ́-gbẹ̀-jọ ibusọ lati wa gbọ iwaasu kan. Bọya arakunrin Palmer tabi ọmọ rẹ, ọkan ninu awọn méjèèji, sọ ijanu ọkọ́ nu nigba ti wọn fẹ ya si igun kan, wọn si ni ijamba ọkọ. Ijamba yii nipa lori Arabinrin Palmer. Ẹ jẹ ki a gbadura.

Ọlọ́run ọwọn, yọ iyawo iranṣẹ Rẹ yii. Iranṣẹ Kristi kekere ti o jẹ alati-lẹyin Rẹ ati olootọ si Ọ. Mo gbadura, Ọlọrun bi emi ati Arakunrin Jack Moore nihin ti n gbe ọwọ lee pe ki O mu larada, ki O si mu ki ara rẹ ya. Ni orukọ Jesu. Amin.

87 Ni ẹṣẹ ọtun, o si n duro fun un? Ọmọkunrin rẹ kekere ya arọ, oni ipalara ni ikun ati ẹyin rẹ. Ẹ jẹ ki a gbadura:

Ọlọ́run ọwọn, jẹ ki Adaba funfun bi ojo didi naa wọ isalẹ ọkan rẹ kia bayi, “a sa A lọgbẹ fun irekọja wa, a pa A lara fun ẹṣẹ wa, pẹlu ina Rẹ a mu wa larada.” Mo bere ki eleyi ri bẹẹ fun arakunrin wa ati fun ọmọkunrin rẹ kekere, ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Irora ti ẹfori ti o lagbara, ati aisan ni ọ̀kan ninu awọn ẹsẹ rẹ ti o n da a laa mu bi o ba ti n siṣẹ.

Ọlọ́run ọwọn fun ọdọmọkunrin yii ni ibùkun iwosan Rẹ, bi awa gẹgẹ bi i iranṣẹ Ọlọrun ti n gbe ọwọ wa lee. Ni oruko Jesu Kristi. Amin.

88 O ni wahala abo, ti ọmọbinrin, o si tun n fẹ gba ibaptisimu Ẹmi Mimọ.

Ọlọrun ọwọn, bi mo ṣe n gba adura igbagbọ fun ọdọmọbinrin yii, jẹ ki wahala ọmọbinrin dopin fun un, ki ibaptisi Ẹmi Mimọ tọ ọ wa labẹ apa iyẹ Adaba kan, ni oruko Jesu Kristi. Amin. Ki Ọlọ́run bukun ọ, arabinrin.

Ohun ti o wu si oju rẹ ati iwosan fun ekeji rẹ ti o nifẹ.

Ọlọrun ọwọn, Ẹ mọ ọkan awọn eniyan. Mo gbadura si Ọ Baba ni orukọ Jesu, pe Ki O fun arakunrin yii ni ẹbẹ rẹ, ni igbọran si Ọrọ Rẹ nipa gbigbe ọwọ lee. Ni orukọ Jesu Kristi. Amin. Ki Ọlọ́run bukun ọ, arakunrin.

O ni ohun kan ti o wu si ẹgbẹ rẹ, ohun rẹ naa ko si dara.

Jesu ọwọn, mo gbadura pe ki O wo arabinrin yii san, mo gbe ọwọ lee ni orukọ Jesu Kristi, pe ko o ri iwosan rẹ gba. Amin. Ki Ọlọ́run bukun o, arabinrin.

Otosi arabinrin, mo ri isoro rẹ, orókún ti o wu, kidinrin, apo itọ ati igbọnwọ ti o ti kuro ni àáyè rẹ.

O o Ọlọ́run Baba, wo ọmọbinrin ọwọn yìi san, Oluwa, mo gbadura bi mo ṣe gbe ọwọ lee ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Ki Ọlọ́run bukun ọ arabinrin, bi o ṣe ri niyẹn…

Njẹ ẹ gbọ iyẹn ṣe ẹ ko gbọ, lori ẹerọ gbohungbohun? Ẹni yoo wu ti o wa… onimọ-ẹrọ, bi o ba yii si oke diẹ, awọn ijọ yii lee gbọ ẹri wọn… ohun ti wọn sọ nigba ti wọn n kọja ni ila adura. Ẹ wa ninu adura fun wọn nigba ti ẹ ba gbọ ọ. Nigba ti mo ba bẹrẹ lati gbadura, ẹyin baa ẹ maa gbadura pẹlu mi.

Ọlọ́run ọwọn, mo gbadura fun arabinrin wa yii pe ki O wo o san, Ọlọrun ọwọn. A n ṣe eleyi nitori pe o jẹ aṣẹ Rẹ. Ni oruko Jesu Kristi. Amin.

89 Ọlọ́run ọwọn, O gbọ ẹri naa, O gbọ ohun ti ọta ti ṣe si arabinrin naa. A n gbiyanju lati mu orukọ Jesu lati ṣẹgun ọta yii, a ti ṣẹgun rẹ na nitori Adaba ti A palara, ti A salọgbẹ ti ṣubu sori ilẹ ni ile Ọlọ́run lati jẹ iṣẹ pe, “O ti pari!” Ẹ gbaa bẹẹ. N jẹ ki o gba iyẹn gbọ, Baba, ni orukọ Jesu.

Ọlọ́run ọwọn, mo gbadura pe ki O wo arabinrin wa yii san. Jẹ ki Adaba Ọlọ́run jẹri si i ni aṣalẹ yii pe Oun ti sẹ e fun un, pe ara rẹ lee da ni orukọ Jesu. Amin.

Ọlọ́run ọwọn, mo gbe ọwọ mi le arakunrin mi ti o duro nihin. O ni igbagbọ ti o to lati de ibi ti o de yii, Oluwa, jẹ ki o gba imularada rẹ ki o si lọ si ori ijoko rẹ pẹlu ara dida. Ni orukọ Jesu.

Ọlọ́run ọwọn, mo gbadura fun arakunrin wa, mo gbe ọwọ lee. Ran iranlọwọ Ọlọ́run ọwọn ki igbagbọ Ọlọ́run ki o lee wọ isalẹ ọkan rẹ ni isisiyi, ki o dabi Abraham, ti o pe gbogbo nnkan ti o wa bi ẹni pe wọn ko si, nitori Ọlọ́run ṣe ileri naa. Ni orukọ Jesu. Amin.

90 Ọlọ́run ọwọn, Iwọ ni O lee ṣe ipinnu ti o tọ. Mo gbadura, Ọlọ́run ọwọn, bi ọdọmọbinrin yii ti beere fun eeyi, jẹ ki o ri gba ni orukọ Jesu. Amin.

Ọlọ́run ọwọn, mo gbe ọwọ mi le arabinrin wa ni igbọran si ohun ti O ni ki a ṣe. Eyi mu wa lọ si ọpọlọpọ ọdun sẹyin, Oluwa, ti a ti pe fun iru ila adura bi eyi sẹyin; sugbọn a mọ ohun ti o sẹlẹ nigba naa, a mọ wi pe Ọlọ́run kan naa ni Ọ loni, bi awọn eniyan ba lee ni igbagbọ kan naa loni. Mo gbadura ni orukọ Jesu fun iwosan arabinrin wa. Amin.

Ọlọrun ọwọn, mo gbe ọwọ mi le arakunrin mi nihin mo si bere fun imularada rẹ, ni oruko Jesu Kristi. Amin.

Baba, mo mu wa si iwaju Rẹ ni aṣalẹ yii arabinrin wa, mo si gbe ọwọ lee lati jẹri pe mo n duro bi ẹlẹri ti okun Rẹ, mo duro bi ẹlẹri awọn iran Rẹ, Ọrọ Rẹ, mo si jẹ ẹlẹri pe Ọlọ́run ni O jẹ. Mo si gbe ọwọ mi lee ni igbọran si Ọrọ Ọlọ́run mi, mo si beere fun iwosan rẹ. Amin.

91 Ọlọ́run ọwọn, mo gbe ọwọ le arakunrin mi ni ọna kan naa, gẹgẹ bi ẹlẹri okun Rẹ. Mo beere fun imularada rẹ ni orukọ Jesu Kristi. Amin. (Ohun ko jade lori Ẹrọ ti n gba ohun silẹ) “Kin ni?”

O ni, “A wo ọkunrin afọju, ti n tun bata ṣe kan ni ibi kan ni Arkansas san laaarọ yi.” Ṣe ẹ mọ isẹlẹ naa, o ti n jade lori ẹrọ radio.

Mo wa ni … mo ro pe, mo wu iwa bi alagabagebe. Mo ni, “Iwọ ko gba gbọ pe otitọ ni ohun ti o ṣẹlẹ naa?” Obinrin naa wi pe, “Bẹẹ ni mo gbagbọ”

Mo wa sọ pe, “N jẹ o gba pe Ọlọ́run lee ṣe iru nnkan bẹẹ loni nigba ti…

O wi pe, “Alagba, mo gbọ eto ẹsin naa.” O wi pe Kristẹni ni mi.“ O wi pe, ”Mo tẹtisi eto ẹsin naa, mo gbọ ohùn ọkunrin ti a wosan naa laaarọ yii, ọkunrin a tun bata ṣe ti o fọju naa. N wọn lee jade kuro ni sọọsi, o n pariwo pupọ ju, lati sọọsi kan de ekeji. Pẹlu ate rẹ lori rẹ ati ọpa rẹ, ti o n ju sihin sọhun, ti o n sare lati sọọsi kan de ekeji nibi gbogbo ni ilu naa. Ti o n kigbe pe, “A ti la mi loju, a ti wo mi san!” “A tun bata ṣe, afọju.”

Mo ni, N jẹ iwọ gba iyẹn gbọ?“

Omọbinrin naa duro nibẹ diẹ, òjò n fọn, o wi pe, “Alagba, bi o ba lee mu mi wọle nibi ti o wa, n o ri baba mi.” Ó rẹ̀ mí wá ni.

Mo ni, “Boya emi ni ẹniti iwọ n wa.”

O gba mi mu ni eti asọ kootu mi, o ni, “Ṣe ẹyin ni oluwosan naa?”

Mo ni, “O ti o, arabinrin, sugbọn emi ni Arakunrin Branham.”

O ni, "Ẹ saanu mi!" Mo ronu nipa otosi afọju Fanny Crosby atijọ, "Nigba ti O n pe awọn miiran, ma kọja mi." "Ṣe ẹ ri i. O ti wo ẹnikan san, O lee wo oun naa san.

Mo gbe ọwọ mi le oju rẹ, mo wi pe, "Jesu ọwọn, ni ọjọ kan n wo agbelebu atijọ kan loju ọna, awọn ejika naa n sẹjẹ, ara ti ko lokun kan ti O n ruu ṣubu labẹ ẹru naa. Ọkunrin kan lati orilẹ-ede alawo dudu ti orukọ rẹ n jẹ Simon ara Cyrene wo, o si gbe agbelebu naa, o ran An lọwọ lati gbee. O da mi loju pe O ranti rẹ, Baba. Ọkan ninu awọn ọmọ Rẹ n ta gbọngbọn ninu okunkun, o damiloju pe Ẹ ranti."

O wi pe, "Ogo ni fun Ọlọ́run! Mo ti riran!"

Mo ni, "Ṣe o lee riran?"

Ọmọbinrin naa wipe, "Bẹẹ ni, alagba,"

Mo ni, "ka awọn imọlẹ yẹn." O si ka wọn. Mo ni, "kin ni awọ asọ kootu ti mo wọ?" O ni, "Ẹ wọ kootu alawọ eeru, pẹlu tai olomi orombo." Bi o ṣe ri ni yẹn, o lee riran.

O o Ọlọ́run n bọwọ fun irẹlẹ. "Eyi ninu ara rẹ ni ohun ti yoo mu wa, ti yoo si mu waye, isẹgun nla ninu ifẹ atọrunwa."

Ọlọ́run ọwọn, ṣaanu, ki O si wo arabinrin mi san ni Orukọ Jesu Kristi. Amin.

92 Ọlọ́run ọwọn, bi mo ṣe mu ọwọ ti ko lagbara, ti o si n hunjọ, Iwọ nikan ni O mọ awọn ti o ti kọja nihin. Mo gbadura, Ọlọrun ọwọn, pe ki ọwọ kan naa ti mo ni ni aṣalẹ yii ti o gbamọ ara bi ọwọ Simon ti ko lokun lọjọ naa lọhun, Oluwa, "Oluwa jẹ ki iranṣẹ Rẹ jẹ maa lọ ni alaafia, nitori bayi mo ti ri igbala Rẹ." Jẹ ki o wa sori rẹ Oluwa, Igbala Rẹ, ki o si mu larada ni Orukọ Jesu. Amin.

93 (Ohun ko jade lori ẹrọti n gba ohun silẹ) Ninu Ipelẹjọ Naa, Ọgbẹni Alaigbagbọ fi ẹsun kan Jesu Kristi. Ṣe ẹ ranti Ipelẹjọ naa? Bi wọn ṣe ni agbejọro ati ohun gbogbo bẹẹ ati ẹni ti o duro fun lagbaja ati lakasegbe. A si ni agbẹjọro ti opẹjọ, Satani, ti o fẹ pe ẹjọ naa, bi a ṣe mu ẹjọ naa wa.

O si sọ pe, ọgbẹni kan, oniyemeji, o dide, o wipe, "Mo gbọ ti oniwaasu kan sọ pe, 'Ta ororo le alaisan lori, Bibeli sọ bẹẹ.' Wọn si ta ororo lemi lori, ara mi ko si da. Omiiran sọ pe, 'Gbe ọwọ le awọn alaisan lori, ara wọn yoo si da". O n gbiyanju lati pe ẹjọ́.

Sugbọn nigba ti ẹlẹri naa jade, bi o ṣe ri niyi. Ọlọ́run sọ fun wọn O ni… A ti … o wi pe, "O ti pe osu mẹfa ti a ti gbe ọwọ le mi Ọrọ Rẹ si sọ pe, "Gbe ọwọ le alaisan ara wọn yoo si da.' A si gbe ọwọ le mi lati ọwọ ọkan ninu awọn iranṣẹ ẹni ami-ororo Rẹ, ara mi kọ si tii da. Nitori naa eke adibọn ni Ọ, nitori Ọrọ Rẹ ko ri bi o ṣesọọ."

94 Nitori naa nigba ti ẹlẹri naa jade sita, oni otitọ naa ni eyi pe otitọ ni Ọrọ Rẹ. Ko fi gbèdeke le igbati yoo ṣẹlẹ, O wi pe, "Awọn ami wọnyii yoo tẹlẹ awọn ti o gbagbo, bi wọn ba gbe ọwọle awọn alaisan, ara wọn yoo da." Ṣe ẹ rii? Ohun ti O sọ niyẹn, "Ara wọn yoo da. Nitori naa, boya o jẹ iṣẹ-iyanu ti o sẹlẹ, lẹsẹkẹsẹ bayi, tabi o jẹ siṣe igbọran si Ọlọ́run, o ku si ọwọ Ọlọ́run nipa aladori ẹni-kọọkan. Ṣe ẹ rii? Sugbọn bi aladori-ẹnikan ba gba a gbọ, emi ko fẹ mo bi o ti pẹ to. O sọ fun Abraham, "Iwọ yoo bi ọmọ kan nipasẹ Sarah." A ko bi ọmọ naa titi ọdun marun-din-logbọn. O sọ fun Noah pe ojo yoo rọ. Noah ni ẹkun omi… a kan ọkọ naa ni ọpọlọpọ ọdun ki ojo naa to rọ. Sugbọn o mọ wi pe yoo rọ. Bibeli sọ wi pe, "Adura igbagbọ yoo gba alaisan naa la Ọlọ́run yoo si gbe wọn dide." Nigba wo? Ko sọ ọ. Olododo ni Ọlọ́run, olotitọ si ni. Saa ka ohun ti Ọrọ Rẹ sọ.

Ohun ti mo ti ṣe ni aṣalẹ yii niyi, mo gbe ọwọ le alaisan. Wayi mo gbagbọ pe a o mu gbogbo wọn larada. Mo gbagbọ fun gbogbo wọn. N jẹ iwọ gba ohun kan naa gbọ? Wayi, ẹ gbagbọ fun gbogbo awọn ti wọn ṣe aisan yii.

95 Obinrin kekere kan wa nihin, O dabi ẹni pe o yẹ kin mọ ọ, mo gbadura fun un ni aṣalẹ ana, nibẹ ninu ila adura, Kin ni orukọ rẹ? Chambers… Chambless. Bi obinrin kekere naa yoo ba ye- ti yoo ba ye gẹgẹ bi ẹnikẹni, a ki ba ti fi aisan kọlu u. O daju pe arẹwa obinrin ni. O si joko sibi yii bayi ti o n gbọn. Ẹni ti o dara, pẹlu ẹmi ti o dara ni. O wa ninu ọdọmọbinrin naa. O si joko sibẹ, o n gbọn bi eyi. Bi eleyi ti ba mi ninu jẹ. Bi n ba ti fẹ… bi n ba ti fẹ!

Nihin ni ọmọde kekere kan wa, obinrin kan joko nihin o gbee lọwọ, ahọn rẹ kekere yọ sita, a n pọn ara rẹ kekere loju. Bawo ni bi eyi ba jẹ Josefu mi kekere? Bi eyi ba jẹ Pọọlu ọmọọmọ mi kekere? Bawo ni bi eyi ba jẹ Rebecca ti o joko nibẹ, tabi Sarah? Bawo ni bi Mrs Simpson nihin jẹ iyawo mi, Mẹda? Bi ọdọkunrin yii ti o joko nihin ba jẹ Billy Pọọlu? Bi obinrin arugbo ti o joko nihin ba jẹ iya a mi? Ranti pe ọmọ ẹnikan ni, arabinrin ẹnikan ni, ọmọbinrin ẹnikan ni, ọmọkunrin ẹnikan ni. s̀e ẹ rii? Arakunrin wọn ni mo jẹ, Olugbala wa ni. Ohun gbogbo ti mo lee ṣe ni … Gbogbo igbagbọ ti mo ni ni n o lo fun wọn. Gbogbo ohun ti mo mọ ni yẹn.

96 Wayi, Oluwa lee fi iran kan han mi. O le sọ fun mi ohun ti o kuna pẹlu ikọọkan wọn. Mo lee fi eyi da ọ loju, ṣe ẹ rii, ẹ mọ bẹẹ. Sugbọn iyẹn ko ni n wo wọn san. Eleyi kii wo wọn san. Rara o, ohun kan ni lati sọkalẹ sinu wọn, ṣe ẹ ri i. Oo

Gẹgẹ bi mo ṣe lee mu ọkan ninu yin ki n baptisi rẹ ni orukọ Oluwa, Jesu Kristi. Eyi ko ni pa ẹṣẹ rẹ. O ti o, o ti o, o ti o, emi ko gbagbọ ninu itẹbọmi ni orukọ Jesu Kristi fun atunbi. Mo gbagbo pee ẹjẹ Kristi n sọ ni di atunbi. Ṣe ẹrii, ki i ṣe omi. Sugbọn wo o, mo lee baptisi, ki n baptisi, sugbọn iwọ yoo wọ inu omi bi ẹlẹṣẹ ti ara rẹ gbẹ o o si jade bi ẹlẹṣẹ ti ara rẹ tutu, wo o ayafi bi o ba ronupiwada tọkan tọkan. Ronupiwada, ki a wa ṣe itẹbọmi fun ọ ni orukọ Jesu Kristi. Ṣe ẹ rii? Ibi ni mo ti tako awọn ẹgbẹ Ọlọ́run jẹ ọkan soso girogiro. A ki i baptisi fun iyi pada igbe aye, rara o, mo gbagbọ wi pe ẹjẹ ni o n fọ ni mọ, kii ṣe omi, ṣe ẹ rii? Ronupiwada, ki a sii baptisi rẹ ni orukọ Jesu Kristi.

97 Wayi, n ọ gbadura. Bi gbogbo awọn wọnyii ti jẹ si i yin, ni wọn jẹ simi, boya ju bẹẹ lọ paapaa ni ọna ibatan.

Wayi i, ẹ jẹ ki a so pọ, ati ọwọ yin pẹlu igbagbọ ati ọwọ emi naa pẹlu igbagbọ, ti a n mu ọwọ Oluwa Jesu sọkalẹ le awọn otosi ti o yaarọ wọnyii. Ṣe ẹ o gbadura pẹlu mi?

(Ohun ko jade lori ẹrọ ti n gba ohun silẹ) Awọn ti wọn ni asọ pelebe pelebe ti o wa fun awọn alaisan ati alarun ẹ le wa mu wọn lẹyin isin. Wayi, ẹ ba mi gbadura fun awọn wọnyii, ṣe ẹ o ṣe bẹẹ?

Ọlọ́run, a dupẹ lọwọ Rẹ, Oluwa fun ohun ti O ṣe ni irọlẹ yii. A dupẹ lọwọ Rẹ ṣilẹ fun imularada ẹni kọọkan ti o wa fun adura. Ọlọ́run ọwọn, mo gbadura lori awọn asọ pelebe pelebe yii, boya fun awọn ti wọn ko ni anfani ati wa fun isin yii, ati awọn ololufẹ wọn ko awọn asọ pelebe pelebe yi wa. Ninu Bibeli a kọ wi pe wọn mu jade lara Pọọlu, aṣọ pelebe pelebe ati awọsọrun kekeke. Awọn ti wọn gbe nigba naa ti gbe niwaju Rẹ. Wọn ti ri O loju popo, wọn si ti ri Ẹmi Rẹ ni igbesi-aye Pọọlu. Wọn si mọ wi pe kii ṣe ọkunrin naa, o jẹ Ẹmi Rẹ ti o gba akoso igbe aye rẹ, nitori a ri Pọọlu ti o nṣe awọn ohun ti O ṣe gẹlẹ.

Ati bayi, Oluwa, awọn eniyan ti oni ti ri Ọlọ́run kan naa ti O n gbe ninu Ijọ Rẹ pẹlu awọn eniyan Rẹ. Wọn si ti mu awọn asọ pelebe pelebe wọnyii wa ki a lee mu lati ihin lọ ba awọn ololufẹ wọn. Jẹ ki o ri bẹẹ, Ọlọ́run, pe ki ikọọkan wọn gba iwosan ni ọna Rẹ. Awa ko beere wi pe ki a ṣe ohunkohun ni ọna Kankan tabi pẹlu iwa ẹda kan, a saa bere ni, “Ni ọna Tirẹ Baba, mu wọn larada.” Fun ogo Ọlọ́run, mo gba adura igbagbọ yii lori rẹ. Ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

98 Mo ti ni akoko idapọ ti o ya nilẹnu, pẹlu igbagbọ yin, ati iwa laaye yin ninu Jesu Kristi. Eyi yoo jẹ ipade ti n o maa ranti fun igba pipẹ fun awọn ohun ti o sẹlẹ: Ifẹ yin, ifi ọwọsọwọpọ yin, ati idapọ yin.

Ati bayi, titi ti a o fi tun pade njẹ ki Ọlọ́run ọrun ki O ma ṣe amọna yin. Ẹni ti O njẹ ki awọn irawọ ki o tan daradara ni alẹ ki O tan imọlẹ si ipa ọna yin nigba ti o ba n ku lọ, njẹ ki O tan imọlẹ si ipa ọna yin pẹlu Irawọ Bethlehem lati ṣe amọna yin si igbe aye ti o jọwọ patapata fun Ọrọ Ọlọ́run, ni adura mi.

Titi a o tun pade, titi a o tun pade
Titi a o tun pade lẹṣẹ Jesu
Titi a o tun pade, titi a o tun pade
Ki Ọlọ́run wa pẹlu yin titi a o tun pade

Wayi, ẹ jẹ ki a dide duro. Igbagbọ mi n wo Ọ (awọn ọrọ ti n jade ko ye ni)

N da o, n o yi iyẹn pada. Mo gbagbọ, pe iyẹn dara.

Igbagbọ mi n wo
Ọdọ-Aguntan Kalfari
Olugbala Ọrun!
Gbo mi bi mo ti n gbadura
Mu gbogbo ẹṣẹ mi kuro
Ah jẹ lati oni lọ ki n
Jẹ Tirẹ patapata

99 Wayi, ẹ jẹ ki a bọ ara wa lọwọ nigba ti a n kọrin

'Gba mo n rin l'okunkun
Ninu ibanujẹ, S'Amona mi
Mu okunkun lọni
Pa ibanujẹ mi rẹ
Ki n ma sako kuro lọdọ Rẹ

Mo ni imọlara aladun bayi, iwọ nkọ?

Lori iyẹ-apa Adaba funfun bii sno

Ọlọ́run ran ifẹ alailabawọn, didun Rẹ
Anu lati oke wa
Lori iyẹ-apa adaba kan
Lori iyẹ-apa Adaba funfun bii sno
Ọlọ́run ran ifẹ alailabawọn, didun Rẹ
Anu lati oke wa
Lori iyẹ-apa adaba kan

Eyi ni iwaasu ipari fun iponlongo ihinrere yii.
Lori iyẹ-apa adaba funfun bi i ojo didi
Ọlọ́run ran ifẹ alailabawọn, didun Rẹ
Ami lati oke wa
Lori iyẹ-apa adaba kan

100 Ẹ tẹ ori yin ba. Gẹgẹ bii ayida agba kẹkẹ ti n kun bi o ṣe n lọ sile, mo gbagbọ pe ẹ n gba kikun ti Ayida agba kẹkẹ ati pipariwo ti Engini naa:
Lori iyẹ-apa adaba funfun bii ojo didi
Ọlọrun ran ifẹ alailabawọn, didun Rẹ
Ami la toke wa
Lori iyẹ-apa adaba kan.

(Arakunrin Branham bẹrẹ si i kọ orin egbe naa pẹlu u kikun)

………………. adaba,
Ọlọ́run ran ifẹ alailabawọn, didun Rẹ
Ami lati oke wa
Lori iyẹ-apa adaba kan

Pẹlu ori yin ni titẹba, mo fa yin le ọwọ …. Arakunrin Noel yin.

Ìwàásù lati ẹnu
William Marrion Branham
"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info